**COURSE GUIDE**

# YOR 212
# YORUBA FOLKTALES

**LÁTI ỌWỌ́** **ỌLAGOKE ALAMU** Ph.D
Department of Linguistics and Nigerian Languages
Ekiti State University, Ado-Ekiti, Nigeria
Professor Ọlagoke Alamu (Course writer)-NOUN
Professor Adesọla Ọlatẹju (Course Editor)-NOUN

**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**

© 2023 by NOUN Press
National Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone
Nnamdi Azikiwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

Printed 2023

ISBN: 978-978-058-231-9

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

**CONTENT** **PAGES**

Àfojúsùn kọ́ọ̀sì…………………………………….. iv
Student's role……………………………………..… iv
Evaluation………………………………………….. iv
Ìlànà máàkì gbígbà…………………………………. iv

## ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ

The course is designed to equip students with

1. adequate skills in the analysis of the Yoruba folktales.
2. expose the students to the world of Yoruba folktales, with reference to the Yoruba world-view, philosophy and culture.
3. educate them on the oralness of Yoruba oral literature.

## STUDENT'S ROLE

The student should use the study material as the major medium of instruction since the method of instruction is the distance learning mode. Each student is expected to study this material prior to the examination.

## EVALUATION

Continuous assessments are carried out in the form of assignments based on this study material. The assignments will constitute 40% of the total score. The examination constitutes 60% of the total score. There will be three Tutor Marked Assignment for the course before the candidate is qualified for the examination.

## ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn bí máàkì gbígbà yóò ṣe rí.

| Ìgbéléwọ̀n | Máàkì |
|---|---|
| Iṣẹ́-ṣíṣe/Àmúṣe módù 1 – 5 | Ogójì (40%) |
| Ìdánwò Àṣekágbá | Ọgọ́ta (60%) |
| Àpapọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

**MAIN COURSE**

# CONTENTS PAGE

## ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ


**Módù Kínní: Ìfáárà…………………………………… 1**

Ìpín kínní: Oríṣi àlọ́, Àbùdá wọn àti Ìwúlò Àlọ́…………. 1
Ìpín kejì: Ìṣíde Àlọ́.......................................................... 5
Ìpín kẹta: Àwọn Èròjà inú Àlọ́………………………… 9

**Módù Kejì: Kókó Ọ̀rọ̀, Ìhun àti Ìfiwàwẹ̀dá…………… 12**

Ìpín kínní: Kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́……………………………. 12
Ìpín kejì: Ìhun-ìtàn àlọ́ àti àbùdá ìtàn………………….. 15
Ìpín kẹta: Ẹ̀dá-ìtàn àti Ìfiwàwẹ̀dá………………………. 19

**Módù Kẹta: Ìlò Èdè àti Bátànì Gbólóhùn**
**Ìṣíde àti Ìparí Àlọ́………………………….. 23**

Ìpín kínní: Ìlò Èdè inú àlọ́………………………………. 23
Ìpín kejì: Bátànì gbólóhùn ìṣíde àti ìparí àlọ́………….... 30

**Módù Kẹrin: Àṣàyàn Àlọ́ Ìjàpá àti Àtúpalẹ̀ wọn……… 33**

Ìpín kínní: Ìjàpá, Àgbò àti Igbá…………………………. 33
Ìpín kejì: Ìjàpá lóyún ìjàǹgbọ̀n………………………… 38
Ìpín kẹta: Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn………………………. 43
Ìpín kẹrin: Ìjàpá, Ajá, Ẹkùn àti Ọdẹ……………………. 48

**Módù Karùn-ún: Àṣàyàn Àlọ́ Olórogún tàbí Àlọ́**
**mìíràn àti Àtúpalẹ̀ wọn……………. 52**

Ìpín kínní: Ìtàn Orogún méjì àti Ọkọ wọn……………... 52
Ìpín kejì: Ìyáálé gbé ọmọ ìyàwó rẹ̀ sínú ọtí.................. 56
Ìpín kẹta: Ìyáálé roko tán............................................. 60
Ìpín kẹrin: Tanimọ̀la àti Orogún ìyá rẹ̀………………… 64

# MÓDÙ KÍNNÍ: ÌFÁÁRÀ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Oríṣi àlọ́ àti Àbùdá wọn
4.2 Ìwúlò Àlọ́
4.2.1 Fún Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.2.2 Fún Ìdárayá
4.2.3 Fífi ìdí òótọ́ múlẹ̀
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Àlọ́ jẹ́ ọ̀kan lára lítíréṣọ̀ àtẹnudẹ́nu Yorùbá tí ó tàn kálẹ̀ ju àwọn lítíréṣọ̀ àtẹnudẹ́nu yòókù lọ. Àwọn ọmọdé ni a máa ń pa àlọ́ fún lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́. Alẹ́ ni a máa ń pa àlọ́ pàápàá nígbà tí òṣùpá bá yọ. Ìdí ni èyí tí ààlọ́ àpagbè fi jẹ́ ọ̀kan lára àwọn eré tí à ń pè ní eré òṣùpá, èyí tí àwọn ọmọdé máa ń ṣe ní ilẹ̀ kááàrọ̀-oò-jíire. Àgbàlagbà kan ni ó máa ń pa àlọ́ fún àwọn ọmọdé.

Àlọ́ jẹ́ àwọn ìtàn tí ó dá lé àṣà àti ìṣe Yorùbá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àṣà Yorùbá bí i ìgbéyàwó, oúnjẹ, aṣọ wíwọ̀, òkú sínsin, àṣà ìranraẹnilọ́wọ́, orin àti ijó ni ó wa nínú àlọ́. Oríṣiríṣi ìmọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá (tí à ń pè ní fìlọ́sọ́fì), èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá, pàápàá nípa Olódùmarè, àwọn òrìṣà, ọdún ìbílẹ̀ àti àwọn ohun mèremère àyíká tí Olódùmarè dá ni ó wà nínú àlọ́. Káàkiri àgbáyé ni a ti ń pa àlọ́. Ó fẹ́rẹ̀ má sí í orílẹ̀ àgbáyé kan tí kò ní àlọ́ tirẹ̀.

Àwọn ìtàn àtinúdá ni àlọ́ jẹ́. A kò mọ ẹni pàtó tí ó dá wọn sílẹ̀ nítorí àtẹnudẹ́nu ni wọ́n. Ṣùgbọ́n báyìí, àwọn òǹkọ̀wé bí i Babalọlá (1979) àti Ọ̀pádọ̀tun (1994) ti ṣe àkójọpọ̀ wọn, wọ́n sì ti di kíkọ sílẹ̀.

Ìpín kínní: Oríṣi àlọ́, Àbùdá wọn àti Ìwúlò Àlọ́
Ìpín kejì: Ìṣíde Àlọ́
Ìpín kẹta: Àwọn Èròjà inú Àlọ́

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó gbọ́dọ̀ le ṣàlàyé:

(1) ìtumọ̀ àlọ́, àti àwọn akópa nínú àlọ́.
(2) oríṣi àlọ́ tí ó wà àti àbùdá wọn.
(3) àwọn ohun tí à ń lo àlọ́ fun.
(4) oríṣiríṣi àṣà àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò Yorùbá (Yorùbá filọ́sọfì) tí ń bẹ nínú àlọ́.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ǹjẹ́ o ti gbọ́ nípa àlọ́ rí?
2. Irú àlọ́ wo ni o ti gbọ́ nípa rẹ̀?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìpín Kínní: Oríṣi Àlọ́ àti Àbùdá wọn

Oríṣi àlọ́ méjì ni Yorùbá ní. Èkínní ni àlọ́ àpagbè tí a tún ń pè ní àlọ́ onítàn (folktale). Èkejì sì ni àlọ́ àpamọ̀ (riddles). Àlọ́ àpagbè, èyí tí kóọ̀sì yìí dá lé jẹ́ àwọn àlọ́ tí ó ní ìtàn nínú, tí ó sì sáábà máa ń dá lé ẹranko kan tí a mọ̀ sí ìjàpá (the tortoise). Àmọ́ kì í ṣe ìjàpá nìkan ni àlọ́ àpagbè máa ń dá lé, ó tún le dá lé àwọn ènìyàn, ṣùgbọ́n ti ìjàpá ni ó wọ́pọ̀ jùlọ. Ìjàpá ni ó sáábà máa ń jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlọ́ Yorùbá.

Oríṣi àlọ́ kejì ni èyí tí à ń pè ní àlọ́ àpamọ̀. Nínú oríṣi àlọ́ yìí, apàlọ́ yóò béèrè ìdáhùn tó rúnilójú tàbí ìbéèrè tí kò lọ tààrà, èyí tí àwọn ọmọdé máa ronú jinlẹ̀ láti wá ìbéèrè sí. Fún àpẹẹrẹ ìhun àlọ́ àpamọ̀ ni èyí:

(i) Apàlọ́: Ààlọ́ o!
Ọmọdé: Ààlọ̀!
Apàlọ́: Kí ló bọ́ sódò tí a kò rí kó?

Ìdáhùn irú àlọ́ yìí gba ìronú jinlẹ̀ láti fèsì sí. Èsì àlọ́ yìí ni 'iyọ̀' (salt). Ìdí èyí sì ni pé tí a bá da iyọ̀ sómi, níṣe ni yóò domi fún ra rẹ̀.

(ii) Apàlọ́: Ààlọ́ o!
Ọmọdé: Ààlọ̀!
Apàlọ́: Òkun ń hó yeye
Ọ̀sà ń hó gbùdù
Alákọrí korí bọ̀ ọ́
Ki ni o?

Ìdáhùn sí àlọ́ yìí ni 'orógùn'. Orógùn ni à ń lò láti ro oúnjẹ nínú omi gbígbóná tí ń hó yeye.

## 4.2 Ìwúlò Àlọ́

Iṣẹ́ mẹ́ta pàtàkì ni à ń fi àlọ́ ṣe:

(1) À ń lò ó fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́. A fi ń kọ́ àwọn ọmọdé lẹ́kọ̀ọ́ pàápàá nípa ìwà ọmọlúàbí. Ìdí ni èyí tí ìwà rere fi máa ń borí ìwà búburú nínú àlọ́.
(2) À ń lò ó fún ìdárayá. À ń fi ìtàn inú àlọ́ dá àwọn ọmọdé lárayá.
(3) À ń lò ó láti fi ìdí òótọ́ múlẹ̀ pàápàá nípa àṣà Yorùbá.

### 4.2.1 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Yorùbá máa ń lo àlọ́ onítàn láti kọ́ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́ ìwà rere tàbí ìwà ọmọlúwàbí. Àwọn ìwà bí i òótọ́ sísọ, ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀, ìbọ̀wọ̀fágbà, àìṣọ̀lẹ, àìṣèmẹ́lẹ́, ìwọ̀ntunwọ̀nsì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ni àwọn ìwà rere tí Yorùbá kà sí ìwà ọmọlúwàbí, èyí tí ó ṣe àwùjọ ní àǹfààní, tí ó sì dára fún ìbágbépọ̀ ẹ̀dá. Yorùbá gbàgbọ́ pé ìwà rere lẹ̀ṣọ́ ènìyàn, ṣùgbọ́n àwọn ìwà bí i olè jíjà, iró pípa, ọ̀lẹ ṣíṣe, ìmẹ́lẹ́ ṣíṣe, ìgbéraga, àìbọ̀wọ̀fágbà, ojúkòkòrò, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ni àwọn ìwà tí Yorùbá bu ẹnu àtẹ́ lù tí wọ́n sì kà sí ìwà búburú. Irú àwọn ìwà yìí ni Yorùbá gbàgbọ́ pé ó ní ìjìyà nínú, tí kò sì ṣe àǹfààní fún àwùjọ àti ìbágbépọ̀ ẹ̀dá.

Àwọn ìwà búburú yìí ni àwọn ìwà tí a gbé wọ ìjàpá nínú àlọ́ onítàn. Àwọn ìwà yìí ni wọ́n sì jẹ́ kí ìjàpá máa jìyà nínú àlọ. Àwọn ìwà búburú ìjàpá ni ó ń mú wàhálà àti ìjìyà bá a.

### 4.2.2 Ìdárayá

Yorùbá máa ń pa àlọ́ láti dá àwọn ọmọdé lárayá, pàápàá lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́ wọn. Ìdí ni èyí tó fi jẹ́ pé alẹ́ ni à ń pa àlọ́, pàápàá, ní àkókò òṣùpá.

Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwọn ọmọdé máa ń gbà kópa nínú àlọ́ nígbà tí a bá ń pa àlọ́ láti dá ara wọn lárayá. Wọ́n lè gbe àwọn orin inú àlọ́, tàbí lu ìlù sí àwọn orin yìí, kí wọ́n sì jó sí i. Ìsínjẹ apàlọ́ máa ń pa àwọn ọmọdé lẹ́rìn-ín. Bákan náà ni àwọn ète tí apàlọ́ ṣe àmúlò, (èyí tí a ó rí níwájú) máa ń jẹ́ kí ìtàn náà dùn létí wọn.

### 4.2.3 Fífi ìdí òótọ́ múlẹ̀

Àwọn àlọ́ onítàn kán wà tí à ń lò láti fi sọ ìdí tí ohun kan fi ṣẹlẹ̀. Irú àwọn àlọ́ bẹ́ẹ̀ ni àkọlé wọn máa ń ní àpólà gbólóhùn yìí: "Ìdí tí…". Fún àpẹẹrẹ 'Ìdí tí Ejò fi ń pa Eku jẹ', 'Ìdí tí Ológbò ṣe ń lé Èkúté kiri', Ìdí tí Abiamọ kì í fi í sin ọmọ délé ọkọ' (Ọ̀pádọ̀tun 1994). Wo àpẹẹrẹ irúfẹ́ yìí sí i ní abẹ́ Módù kẹta.

## 5.0 ÌSỌNIṢÓKÍ

Nínú ìpín yìí, kókó pàtàkì méjì ni a yẹ̀wò. Èkíní ni oríṣi àlọ́ tó wà àti àbùdá ìkọ̀ọ̀kan wọn. Oríṣi àlọ́ kìíní ni àlọ́ àpagbè, èyí tí a tún ń pè ní àlọ́ onítàn, èyí tí kọ́ọ̀sì yìí dá lérí. Èkejì sì ni àlọ́ àpamọ̀, èyí tí kò ní ìtàn nínú tí ó ní ìdáhùn sí ìbéèrè nínú. Kókó kejì tí a yẹ̀wò niìwúlò àlọ́ tàbí iṣẹ́ tí àlọ́ ń ṣe. Àwọn kókó mẹ́ta yìí ni: ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ìdárayá àti fífi ìdí òótọ́ múlẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Dárúkọ oríṣi àlọ́ tó wà.

2. Kínni àwọn àbùdá àlọ́ kọ̀ọ̀kan?

3. Kín ni ìwúlò àlọ́?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Babalọlá, A. (1979) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá (Apá kejì)*. Ibadan: University Press

Ojo, O. *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yannibo*. Ikeja: Longman Nigeria Ltd.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ìbàdàn: Y-Books.

# ÌPÍN KEJÌ: ÌṢÍDE ÀLỌ́ ÀPAGBÈ/ONÍTÀN

**Àkóónú**


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  4.1 Àwọn ọ̀nà tí à ń gbà ṣíde àlọ́
    4.1.1 Lílo àlọ́ àpamọ̀
    4.1.2 Lílo ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní abẹ́ ìpínyìí, ohun tí a ó gbéyẹ̀wò niàwọn oríṣi ọ̀nà tí a fi ń ṣíde tàbí bẹ̀rẹ̀ àlọ́.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI AFOJÚSÙN

Ní ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o gbọ́dọ̀ lè mọ:

(1) àwọnoríṣi ọ̀nà tí a fi ń ṣíde àlọ́
(2) àpẹẹrẹ méjì ó kéré tán tí à ń lò láti ṣíde àlọ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ǹjẹ́ o mọ ọ̀nà tí à ń gbà bẹ̀rẹ̀ àlọ́?
2. Èwo ni o mọ̀ nínú ìbẹ̀rẹ̀ tàbí ìṣíde àlọ́ yìí?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àwọn oríṣi ọ̀nà tí a fi ń ṣíde àlọ́

### 4.1.1 LÍLO ÀLỌ́ ÀPAMỌ̀

Kí a tó pa àlọ́ onítàn, àlọ́ àpamọ̀ ni apàlọ́ kọ́kọ́ máa ń fi ṣíde tàbí bẹ̀rẹ̀. Apàlọ́ máa ń lo ọgbọ́n yìí láti ta àwọn ọmọdé (olùgbọ́) jí àti láti pèsè ọkàn wọn sílẹ̀ fún àlọ́-onítàn náà. Fún àpẹẹrẹ apàlọ́ lè bẹ̀rẹ̀ báyìí:

Apàlọ́: Ààlọ́ o!
Àwọn ọmọ: Ààlọ̀!
Apàlọ́: Kí ló ń lọ lójúde ọba tí kò kí ọba?

Nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, apàlọ́ pe àkíyèsí àwọn ọmọ láti múrasílẹ̀ láti gbọ́ àlọ́ tí ó fẹ́ pa.Èyí ló mú kí àwọn ọmọ náà fèsì sí gbólóhùn àkọ́kọ́ apàlọ́ nípa sísọ pé 'ààlọ̀'. Lẹ́yìn èyí ni apàlọ́ yóò wá gbé àlọ́ àpamọ̀ rẹ̀ kalẹ̀, èyí tí àwọn ọmọdé náà yóò ronú jinlẹ̀ sí, kí ọ̀kan nínú wọn tí ó nawọ́ yóò dáhùn nípa sísọ pé 'Èmi mọ̀ ọ́ ọ́n'. Lẹ́yìn èyí ni ọmọ náà yóò dáhùn pé 'òjò'. Tí ọmọ náà bá gba ìdáhùn, apàlọ́ yóò sọ pé 'o gbà á o'.'Bí ọmọ náà bá sì ṣi ìdáhùn sí àlọ́ àpamọ̀ náà, apàlọ́yóò ní 'hún ùn' ó ṣì í o'. Apàlọ́ yóò sì tún pe ẹlòmíràn títí tí a ó fi mọ ìdáhùn sí àlọ́ àpamọ̀ náà. Nígbà mìíràn, apàlọ́ ni yóò fi ẹnu ara rẹ̀ túmọ̀ àlọ́ náà bí kò bá sí ẹni tí ó mọ ìdáhùn sí àlọ́ àpamọ̀ náà láàrin àwọn ọmọdé náà.

### 3.1.2 Lílo Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì

Lẹ́yìn tí apàlọ́ bá lo àlọ́ àpamọ̀ láti ta àwọn ọmọ jí àti láti pèsè ọkàn wọn sílẹ̀ fún àlọ́-onítàn náà, ní ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì kan yóò wáyé láàrin apàlọ́ àti àwọn ọmọdé, tí ó jẹ́ olùgbọ́ rẹ̀. Àpẹẹrẹ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì náà nìyí, ó sì jẹ́ ọ̀nà tí à ń gbà ṣíde àlọ́-onítàn:

Apàlọ́: Ààlọ́ o
Àwọn ọmọdé: Ààlọ̀
Apàlọ́: Ní ọjọ́ kan…
Àwọn ọmọdé: Ọjọ́ kan kìí tán láyé
Apàlọ́: Ní ìgbà kan…
Àwọn ọmọdé: Ìgbà kan ń lọ, ìgbà kan ń bọ̀, ọjọ́ ń gorí ọjọ́.
Apàlọ́: Bàbá kan wà
Àwọn ọmọdé: Ó wà bí ẹ̀wà
… … …

Lẹ́yìn ìṣíde àti ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì yìí ni apàlọ́ yóò bẹ̀rẹ̀ ìtàn tí ó fẹ́ sọ.

Yàtọ̀ sí àpẹẹrẹ òkè yìí, ọ̀nà mìíràn wà tí apàlọ́ lè lò láti ṣíde àlọ́ rẹ̀. Àpẹẹrẹ kejì ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

Apàlọ́: Ààlọ́ o!
Àwọn ọmọdé: Ààlọ̀!
Apàlọ́: Àlọ́ mi dá fùrùgbágbòó
Àwọn ọmọdé: Kó má gbágbòó ọmọ mi lọ
Apàlọ́: Ó dá lérí Ìjàpá Tìrókò ọkọ Yánníbo tó ń lọ láàrin ẹ̀pà
tó ní ọpẹ́lọpẹ́ pé òun ga.
… … …

Nínú àpẹẹrẹ kejì ni a tún ti rí àpẹẹrẹ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì mìíràn èyí tí ó yàtọ̀ díẹ̀ sí àpẹẹrẹ kínní. Irú ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì báyìí, níbi tí àwọn ọmọdé máa ń fèsì sí ọ̀rọ̀ apàlọ́ náà máa ń jẹ́ kí wọ́n múrasílẹ̀ láti gbọ́ àlọ́ onítàn tí apàlọ́ fẹ́ pa.Irú ìṣíde kejì yìí ní ẹ̀fẹ̀ nínú, èyí tí ó máa ń mú àwọn ọmọdé rẹ́rìn-ín. Gbogbo wa la mọ̀ pé igi ẹ̀pà kì í ga rara. Díẹ̀ náà sì ni Ìjàpá fi ga ju ẹ̀pà lọ. Lẹ́yìn ìṣíde yìí ni Apàlọ́ yóò bẹ̀rẹ̀ sí sọ ìtàn rẹ̀.

## 5.0 ÌSỌNIṢÓKÍ

A ti fún wa ní àpẹẹrẹ oríṣiríṣi ọ̀nà tí apàlọ́ ń gbà láti ṣíde àlọ́. Apàlọ́ kọ́kọ́ máa ń lo àlọ́ àpamọ̀ láti ta àwọn ọmọ jí tàbí láti mú àwọn ọmọ lára sílẹ̀ láti gbọ́ àlọ́ onítàn tàbí àpagbè. Ọ̀nà kejì tí apàlọ́ ń gbà ṣíde àlọ́ ni lílo ìsọ̀rọ̀ngbèsì èyí tí a ti fún wa ní àpẹẹrẹ rẹ̀ ní 3.1.2.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Kọ oríṣi àpẹẹrẹ méjì tí apàlọ́ ń lò láti ṣíde àlọ́ sílẹ̀.

2. Kín ni àwọn ìdí tí apàlọ́ fi ń lo irú ìṣíde yìí.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Amọo, T. A. (1988) Yorùbá Ọdún Kìn-ín-ní. Ibadan: Evans Brothers.

Ogundeji, P.A. (1991) Introduction to Yoruba Oral Literature. Ibadan: Dept. of Adult Education, University of Ibadan.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) Àṣàyàn àlọ́ onítàn. Ibadan: Y – Books.

# ÌPÍN KẸTA ÀWỌN ÈRÒJÀ INÚ ÀLỌ́

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àwọn Èròjà inú Àlọ́
4.1.1 Orin
4.1.2 Ìsínjẹ
5.0 Ìsọniṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Oríṣiríṣi èròjà ni apàlọ́ máa ń lò láti gbé àlọ́ kalẹ̀. Àwọn èròjà wọ̀nyí bí i orin àti ìsínjẹ ni àwọn ète ti apàlọ́ máa ń lo láti jẹ kí àlọ́ náà dùn àti pa àwọn ọmọdé lẹ́rìn-ín. Àwọn èròjà yìí ni a ó mẹ́nubà lábẹ́ ìpín yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Ní ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ lè mọ:

(1) ipa tí orin kó nínú àlọ́
(2) ìwúlò orin nínú àlọ́
(3) àwọn ọ̀nà ìsínjẹ inú àlọ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Dárúkọ àwọn èròjà tó máa ń wà nínú àlọ́
2. Kín ni ìwúlò orin nínú àlọ́?
3. Kọ orin àlọ́ kan tí o mọ̀.

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Àwọn Èròjà inú Àlọ́

### 4.1.1 Orin

Oríṣi ète ni apàlọ́ lè lò láti mú ìtàn rẹ̀ dùn àti láti jẹ́ kí àwọn ọmọdé gbádùn ìtàn náà. Ọ̀kan nínú àwọn ète yìí ni orin. Irú orin inú àlọ́ yìí máa ń ní bátànì lílé àti ègbè. Apàlọ́ ni yóò máa lé orin, àwọn ọmọdé yóò sì máa gbè é. Fún àpẹẹrẹ, ẹ jẹ́ kí á wo orin àlọ́ yìí láti inú ìtàn 'Ìjàpá àti Ìyá-Ẹlẹ́pà:

(i) Lílé: Ẹlẹ́pà yìí, ẹlẹ́pà yìí o
Ègbè: Pẹrẹpẹrẹpẹ̀ú
Lílé: Ò bá jó lọ bí Ọ̀yọ́ Ilé
Ègbè: Pẹrẹpẹrẹpẹ̀ú
Lílé: Ò bá jó lọ bí Ọ̀fà Mọjọ̀
Ègbè: Pẹrẹpẹrẹpẹ̀ú
Lílé: Ǹ bá wò dí igbá dè ọ́.
Ègbè: Pẹrẹpẹrẹpẹ̀ú
Lílé: Ẹ̀pà pẹ̀ú, ẹ̀pà pẹ̀ú
Ègbè: Pẹrẹpẹrẹpẹ̀ú
Lílé: Ẹ̀pà pẹ̀ú, ẹ̀pà pẹ̀ú
Ègbè: Pẹrẹpẹrẹpẹ̀ú

Àpẹẹrẹ mìíràn nìyí láti inú 'Ìtàn Orogún Méjì àti Ọkọ Wọn'

(ii) Lílé: Gbewé mi, gbewé mi jẹ
Ègbè: Àgbò gbewé mi jẹ
Lílé: Ọdún kẹta ọkọ́ ti lọ
Ègbè: Àgbò gbewé mi jẹ
Lílé: Èmi ò rìnnà bọ́kùnrin pàdé
Ègbè: Àgbò gbewé mi jẹ
Lílé: Ọkùnrin ó tẹ́ní fún èmi sùn rí
Ègbè: Àgbò gbewé mi jẹ

Láàrin ìtàn ni apàlọ́ ti máa ń dá orin, tí àwọn ọmọdé yóò sì dìde láti jó, pàtẹ́wọ́ tàbí lu ìlù sí i. Ní ìgbà mìíràn, orin inú àlọ́ àpagbè tàbí onítàn ni ó mú un yàtọ̀ sí àlọ́ àpamọ̀, èyí tí kò ní orin nínú.
Oríṣiríṣi ni ìwúlò orin nínú àlọ́:

a) Ó máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé gbádùn ìtàn náà dáradára.
b) Ó máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé kópa nínú ìtàn náà.
d) À ń lò ó láti má jẹ́ kí ìtàn sú àwọn ọmọdé náà, kí wọn kí ó má ba à sùn lọ.
e) Ó ń jẹ́ kí ìtàn kí ó tẹ̀síwájú.

### 4.1.2 ÌSÍNJẸ

Ìsínjẹ ni ète mìíràn tí apàlọ́ máa ń lò láti mú kí ìtàn rẹ dùn. Ìsínjẹ ni fífi ara tàbí ẹ̀yà ara sọ̀rọ̀ láti ṣe ìsínjẹ àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú àlọ́ náà. Lílo irú ète yìí máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé gbádùn àlọ́ onítàn naà dáradára nítorí pé ìsínjẹ lè pani lẹ́rìn-ín.

Nínú ìsínjẹ, apàlọ́ lè rán imú sọ̀rọ̀ láti sín ẹ̀dá-ìtànkan jẹ. Kò sí ẹ̀dá-ìtàn tí apàlọ́ kò lè sínjẹ. Afọ́jú ni o, olóyún ni o, arọ ni o, ó sì lè jẹ́ ẹni tí ó ga tàbí ẹni kúkurú.

Ní kúkurú, apàlọ́ máa ń lo ìsínjẹ láti sín ìṣesí, ìhùwàsí, ìrísí àti ìsọ̀rọ̀sí ẹ̀dá-ìtàn inú àlọ́ tí ó ń pa jẹ. Ète ìsínjẹ lílò yìí máa ń jẹ́ kí ìtàn náà dùn, kí àwọn ọmọdé gbádùn rẹ̀, kí wọn sì tún rò pé òótọ́/òtítọ́ ni ìtàn náà.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Lábẹ́ ìpín yìí, a ti ṣe àgbéyẹ̀wò orin gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ète tí apàlọ́ ń lò láti mú kí ìtàn rẹ̀ dùn.A ṣe àkíyèsí pé orin inú àlọ́ máa ń ní bátànì lílé àti ègbè. Bákan náà, ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìwúlò orin. Orin máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé gbádùn ìtàn náà dáradára; ó ń jẹ́ kí àwọn ọmọdé kópa nínú ìtàn kí ìtàn náà má ba à sú wọn. Ète kejì tí àwọn apàlọ́ ń lò láti gbé àlọ́ kalẹ̀ ni ìsínjẹ. Èyí ni apàló ń lò láti sín ìṣesí, ìhùwàsí àti ìrísí ẹ̀dá-ìtàn jẹ.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Bátànì wo ni orin inú àlọ́ ní? Fi orin inú àlọ́ kan ṣe àpẹẹrẹ.
2. Kọ ìwúlò orin inú àlọ́ sílẹ̀.
3. Kí ni ìsínjẹ?
4. Kí ni ìwúlò ìsínjẹ?
5. Àwọn ohun mẹ́rin wo ni apàlọ́ máa ń sínjẹ lára ẹ̀dá-ìtàn?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

1. Babalọlá, A. (1979) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá (Apá kínní).* Ibadan: University Press.

2. Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn àlọ́ onítàn.* Ibadan: Y – Books.

# MÓDÙ KEJÌ: KÓKÓ Ọ̀RỌ̀, ÌHUN ÌTÀN ÀTI ÌFÌWÀWẸ̀DÁ

**Ìfáárà**

Lábẹ́ Módù yìí, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí àlọ́ onítàn máa ń dá lé. Lẹ́yìn èyí ni a ó mẹ́nuba ìhun ìtàn àti ìfiwàwẹ̀dá.

Ìpín kínní: Kókó ọ̀rọ̀ inú àlọ́-onítàn
Ìpín kejì: Ìhun ìtàn àti àbùdá rẹ̀.
Ìpín kẹta: Ìfiwàwẹ̀dá

## ÌPÍN KÍNNÍ: KÓKÓ Ọ̀RỌ̀ INÚ ÀLỌ́-ONÍTÀN

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kókó ọ̀rọ̀
4.1.1 Ẹ̀san
4.1.2 Ìdí Abájọ
4.1.3 Orogún ṣíṣe
4.1.4 Ìdánwò
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Kókó ọ̀rọ̀ ni òye, ẹ̀kọ́, tàbí ọgbọ́n tí asọ̀tàn tàbí apàlọ́ kan fẹ́ fi kọ́ wa nínú ìtàn rẹ̀. Kókó ọ̀rọ̀ yìí niàhunpọ̀ ìtàn rọ̀ mọ́. Bí a bá fẹ́ mọ kókó ìtàn, a ní láti wo àhunpọ̀ ìtàn náà dáadáa àti ìbáṣepọ̀ àti ìkọlura tó wáyé láàrin àwọn ẹ̀dá-ìtàn, èyí tí ó mú ìtàn náà tẹ̀síwájú.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ lè sọ àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí àlọ́-onítàn ní àti ìdí tí a fi gbé àwọn kókó yìí kalẹ̀ nípa lílo bátànì ìhun ìtàn náà.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kí ni ìtumọ̀ kókó àlọ́?
2. Fún wa ní àpẹrẹ kókó àlọ́ kan tí o mọ̀.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Kókó ọ̀rọ̀

#### 4.1.1 Ẹ̀san

Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ohun tí ènìyàn tàbí ẹ̀dá kan bá gbìn ni yóò kà á. Ẹni tí ó ṣe rere á ríre, ẹni tó sì ṣìkà, á ríkà, àtoore àtìkà, ọ̀kan kìí gbé. Ìdí ni èyí tí ẹ̀san fi jẹ́ ọ̀kan lára kókó pàtàkì tó wà nínú àlọ-onítàn. Dandan ni kí ẹ̀dá-ìtàn kan gba ẹ̀san ìwà rere tó hù tàbí ìwà búburú.

Gẹ́gẹ́ bí olú ẹ̀dá-ìtàn àlọ́, ìdí ni èyí tí a fi ń fi ìyà jẹ ìjàpá nítorí àwọn ìwà búburú tó ń hù. Fún àpẹẹrẹ, ìwà olè tí ìjàpá hù nínú ìtàn 'Ìjàpá àti Ìyá Alákàrà'níbi tí ó ti ń lọ jí àkàrà ni ó mú kí ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀ kan pa á. Bákan náà, ìwà ọ̀dàlẹ̀, ìwọra, ìmọtaraẹni-nìkan, olè àti àìṣòótọ́ ìjàpá ló mú kí ó kú nínú ìtàn 'Ìjàpá àti Àdàbà Jọ Dá Oko Kan'.

#### 4.1.2 Ìdí-abájọ

Àlọ́-onítàn máa ń ṣe àlàyé ohun tí ó mú kí ohun kan rí bí ó ṣe rí. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni èyí máa ń jẹyọ ní ìparí àlọ́ tàbí nínú àkọlé ìtàn gan-an fúnrarẹ̀. A rí àpẹẹrẹ èyí nínú àkọlé àlọ́-onítàn tí Babalọla (1973) ṣe àkójọpọ̀ rẹ̀. Àkọlé yìí ni 'Ìdí tí orí Ìjàpá fi pá' àwọn àkọlé tí ó jọ àkọlé tí a mẹ́nubà lókè yìí. Fún àpẹẹrẹ 'Ìdí tí ọ̀run fi jìnnà sí ayé', 'Ìdí tí ológbò fi ń pa èkúté jẹ' àti 'Ìdí tí ẹ̀yìn ìjàpá ṣe rí kángunkàngun', 'Ìdí tí igúnnugun fi pá lórí'.

#### 4.1.3 Orogún ṣíṣe

Nínú àwọn ìtàn àlọ́ mìíràn tàbí àwọn àlọ́ olórogúnni a ti máa ń rí kókó-ìtàn yìí. A tún lè pe àwọn oríṣi ìtàn tí a ti ń rí kókó yìí ní àlọ́ olórogún. Owú jíjẹ láàrin ìyáálé àti ìyàwó ni ó máa ń fa ìjà orogún. Nínú irú àlọ́ báyìí, ìyáálé ni ó máa ń kórìíra ìyàwó, tí yóò sì ní dandan kí ó bá ohun wá nǹkan ohun kan tí ó sọnù. Ó lè jẹ́ ìgbákọ tí ìyàwó yá lọ́wọ́ ìyáálé, tí odò sì gbé e lọ. Irú ìyáálé bẹ́ẹ̀ yóò ní dandan ìgbákọ òun tí odò gbé lọ ni

òun fẹ́. Irú ìwà búburú yìí àti ìwà ẹ̀san yìí, ni yóò mú ìyàwó rin ìrìn-àjò lọ inú igbó kan níbi tí ẹ̀mí àìrí kan yóò ti ràn án lọ́wọ́ láti rí ohun tó ń wá. Ìfaradà àti ìforítì ni ìyàwó bẹ́ẹ̀ fi ń borí irú ìṣòro báyìí.

### 4.1.4 Ìdánwò

Ìdánwò máa ń jẹyọ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àlọ́ olórogún. Nínú akitiyan ìyàwó láti wá ohun ìyáálé rẹ̀ tó sọnù tàbí tí ó bàjẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀ ni yóò ti bá ìdánwò pàdé. Ìyàwó yìí lè rin ìrìn-àjò lọ inú igbó kan tàbí ìlú òdì kejì láti ṣàwárí ohun tí ìyáálé rẹ̀ pọn ọ́n ní dandan tó fẹ́ gbà padà lọ́wọ́ rẹ̀ láti gbẹ̀san. Nínú ìrìn-àjò yìí ni yóò ti bá iwin tàbí bàbá arúgbó kan tí yóò gbé iṣẹ́ tàbí ìdánwò fún un láti ṣe, kí ó tó rí ohun tó ń wá. Ó lè ní kí ó hú igi ńlá kan lááárín àkókò kékeré kan. Ìgbà mìíràn, arúgbó tàbí iwin yìí lè ní kí ó gbin àgbàdo tí yóò hù lóòjọ́. Irú ìṣòro yìí ni ìyàwó máa ń bá pàdé. Ṣùgbọ́n ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni ìrànlọ́wọ́ yóò dé nítorí inú rere rẹ̀. Ìrànlọ́wọ́ yìí lè jẹ́ iwin mìíràn tàbí ìyá rẹ̀ tí ó ti kú. Àwọn yìí ni yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ìyàwó bẹ́ẹ̀ láti ṣe ìdánwò yìí ní àṣeyọrí.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn olú kókó tí ó sáábà máa ń jẹyọ nínú àlọ́-onítàn. A sì ti ṣàlàyé ohun tí kókó-ọ̀rọ̀ jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ohun kan pàtó tí ìtàn dá lérí. Lára àwọn kókó ọ̀rọ̀ tó máa ń jẹyọ nínú àlọ́ ni: ẹ̀san, ìdí abájọ, orogún ṣíṣe àti ìdánwò.

## 5.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Kí ni ìtumọ̀tí o lè fún kókó-ọ̀rọ̀?
2. Olú kókó-ìtàn mélòó ni ó wà nínú àlọ́-onítàn?
3. Ṣe àpèjúwe olú kókó-ìtàn kọ̀ọ̀kan.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ogundeji, P.A. (1991) *Introduction to Yoruba Oral Literature*. Ibadan: Department of Adult Education, University of Ibadan. pp. 30 – 38.

# ÌPÍN KEJÌ: ÌHUN ÀTI ÀBÙDÁ ÌHUN ÌTÀN

**Àkóónú**


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Àbùdá ìhun ìtàn
  4.2.1 Àṣeṣtúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀
  4.2.2 Àyípadà ìgbà
  4.2.3 Ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì
  4.2.4 Ìrànlọ́wọ́
  4.2.5 Ibùdó ìṣẹ̀lẹ̀
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Níbí yìí, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò ìhun ìtàn àti àwọn àbùdá tí ìhun ìtàn máa ń ní. Èyí ṣe pàtàkì nítorí àwọn èròjà yìí ni a lò láti gbé ìtàn kalẹ̀.

Ìtàn yàtọ̀ sí sísọ ìtàn kan ní ṣókí. Ó yàtọ̀ sí sísọ ìtàn lásán. Àwọn ọ̀nà tí a gbà gbé ìtàn kalẹ̀ tàbí hun ìtàn pọ̀ ni à ń pè ní ìhun-ìtàn. Ìhun ìtàn àlọ́ kì í lọ́júpọ̀ rárá, tàárà ló máa ń lọ.Àlọ́-onítàn ní àwọn ọ̀nà tí a fi gbé e kalẹ̀ èyí tí a lè pè ní àbùdá ìhun-ìtàn.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le;

(1) sọ ìtumọ̀ àhunpọ̀-ìtàn
(2) ṣàlàyé àwọn àbùdá ìhun-ìtàn máràárùn tí a ó mẹ́nubà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Bátànì won i ìtàn inú àlọ́ máa ń ní?
2. Ǹ jẹ́ o mọ nípa àbùdá ìhun-ìtàn?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Àbùdá Ìhun-ìtàn

### 4.1.1 Àṣeṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀

Ṣíṣe ohun kan náà ju ẹ̀ẹ̀kan tàbí ẹ̀ẹ̀mejì lọ nínú àlọ́ ni à ń pè ní àṣeṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀. A rí àpẹẹrẹ èyí nínú ìtàn 'Ìjàpá, Àgbẹ̀ àti àwọn ọmọ rẹ̀'.Àṣeṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ ṣẹlẹ̀ nígbà tí ìjàpá lọ sí oko àgbẹ̀ láti lọ jí erèé (ẹ̀wà) ní ẹ̀ẹ̀mẹta. Lákọ̀ọ́kọ́, gbogbo àwọn ọmọ àgbẹ̀ yìí àti ìyàwó rẹ̀ ni ìjàpá kọrin fún nínú òkùnkùn tí gbogbo wọn sì sálọ fi erèé sílẹ̀ kí ìjàpá tó jí erèé lọ. Ẹnú ya àgbẹ̀ gidigidi nígbà tí wọ́n ròyìn fún un nípa ohun tó ṣẹlẹ̀ lóko, ó sì pinnu láti tẹ̀lé àwọn ọmọ àti òṣìṣẹ́ rẹ̀ ní ọjọ́ kejì lọ wo ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lóko. Nígbà tí ilẹ̀ ṣú ni ìjàpá tún kọ orin abàmì rẹ̀, èyí náà ba àgbẹ̀ lẹ́rù ó sì sálọ. Ẹ̀ẹ̀kẹta ni ọwọ́ tó tẹ ìjàpá, tí ó já sí kòtò tí babaláwo àti àgbẹ̀ gbẹ́, tí igi ṣoṣoro ṣoṣoro tí wọ́n rì mọ́ kòtò sì gún ìjàpá pa.

Láàrin àṣeṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ báyìí ni orin àlọ́ tí ń jẹyọ. Èyí sì fi àyè sílẹ̀ fún àwọn ọmọdé tó ń gbọ́ àlọ́ onítàn láti kópa nínú àlọ́ náà nípa gbígbe orin, ìlù lílù àti ijó jíjó.

### 4.1.2 Àyípadà ìgbà

Nínú àyípadà ìgbà ni a ti ń rí kí ìgbà yí padà fún ẹ̀dá-ìtàn kan. Ẹni tí ó lọ́lá ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn lè di tálákà ní ìparí.Bákan náà, ẹni tí ó ti tálákà lè di ọlọ́lá tàbí olówó.Ẹni tí ó sì ti ń gbé láàrin ènìyàn lè di ẹni tí ó ń gbé inú igbó. Àpẹẹrẹ ìtàn báyìí pọ̀ nínú ìtàn olórogún. Bákan náà, ni ó wà nínú ìtàn ìjàpá ṣùgbọ́n nínú ìtàn olórogún ni ó ti wọ́pọ̀ jùlọ.

Nínú ìtàn "Ìjàpá sọ Àparò di èrò Igbó", àyípadà ìgbà ṣẹlẹ̀ sí Àparò ẹni tí ó ti ń gbé ààrin ìlú tó wá di èrò inú igbó nígbà tí àwọn ẹranko yòókù rí i pé olè ni.

Bákan náà, ni a rí àpẹẹrẹ àyípadà ìgbà nínú ìtàn 'Ìjàpá, Abuké Ọ̀ṣìn àti Ìgbín'. Lẹ́yìn tí ìjàpá pa Abuké Ọ̀ṣìn ó parọ́ mọ́ Ìgbín pé òun ló pa á. Nígbà tí wọ́n fẹ́ pa Ìgbín ó bèèrè fún ọgbọ́n kan láti mọ ìdí òótọ́. Nígbà tí Ìjàpá rò pé ọba tí dá Ìgbín lọ́lá, ó jẹ́wọ́ pé òun lòún pa Abuké Ọ̀ṣìn, ní ìrètí pé ọba yóò dá òun lọ́lá. Ṣùgbọ́n pípa ni a pa Ìjàpá fún ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀.

### 4.1.3 Ìṣẹ̀lẹ̀ Àyísódì

Gẹ́gẹ́ bí Ògúndìjì (1991: 34) ṣe wí, "ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì máa ń wáyé nínú àlọ́-onítàn nígbà tí àyọrísí ìgbésẹ̀ ti ẹ̀dá-ìtàn kan gbé bá jẹ́ àyísódì tàbí òdìkejì àyọrísí ìgbésẹ̀ kan náà tí ẹ̀dá ìtàn yìí tàbí ẹ̀dá ìtàn mìíràn gbé. Ìtumọ̀ èyí ni pé òdìkejì tàbí àyísódì àyọrísí ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ni ó ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn tí ẹ̀dá-ìtàn kan tún gbé irú ìgbésẹ̀ àkọkọ́ yìí.

A máa ń rí àpẹẹrẹ ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì báyìí nínú ìtàn olórogún tàbí ìyàwó àti ìyáálé. Ìyàwó yóò rin ìrìn-àjò lọ sí ìlú òdìkejì tàbí inú igbó aginjù láti ṣe àwárí ohun ìyáálé rẹ kan tí ó sọnù tàbí bàjẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀. Nínú ìrìn-àjò yìí ni yóò ti bá aláàánú kan pàdé, eni tí yóò ṣoore fún un. Nípa èyí ìyàwó lè di ọlọ́rọ̀.Bí ìyáálé bá rí irú ọrọ̀ tí ìyàwó ní yìí, òun náà yóò pinnu láti rin irú ìrìn-àjò bẹ́ẹ̀. Ṣùgbọ́n ní ìgbẹ̀yìn ìyà, ikú àti ẹ̀sín ni irú ìyáálé bẹ́ẹ̀ máa ń bá pàdé.

### 4.1.4 Ìrànlọ́wọ́

Nígbà tí wàhálà tí kò ní ọ̀nà àbáyọ bá dé bá olú ẹ̀dá-ìtàn, ìrànlọ́wọ́ àìrótẹ́lẹ̀ máa ń dé bá olú ẹ̀dá-ìtàn bẹ́ẹ̀.Ìrànlọ́wọ́ àìròtẹ́lẹ̀ yìí máa ń dà bí i iṣẹ́ ìyanu tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ mérìíírí. Irú ìrànlọ́wọ́ báyìí lè wá láti ọwọ́ bàbá tàbí olú ẹ̀dá-ìtàn kan tí ó ti kú tí ó sì rí irú ìyà tí ó ń jẹ ọmọ rẹ̀, nípa iṣẹ́ ńlá tàbí ìdánwò tí ó ń bẹ níwájú rẹ̀, tí ó sì ní láti ṣe kí ó tó ní àṣeyọrí. Irú ìrànlọ́wọ́ báyìí máa ń jẹyọ nínú àwọn ìtàn tí kókó ọ̀rọ̀ wọn jẹ mọ́ ìdánwò.

### 4.1.5 Ibùdó-ìṣẹ̀lẹ̀

Ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn àlọ́ kì í sáábà ní ibùdó-ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ní orúkọ gidi tàbí orúkọ ìlú. Ìdí ni èyí tí a fi máa ń rí ìpèdè bíi 'Ní ìgbà láéláé', 'Ní ìlú Ìjàpá'. Kò sí ibi tí ìtàn àlọ́ kò ti lè ṣẹlẹ̀. Ó lè jẹ́ ní ọ̀run, lábẹ́ omi òkun àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nítorí ìdí èyí ni a fi mọ̀ pé ìṣẹ̀lẹ̀ mérìíìrí ni ìṣẹ̀lẹ̀ ìtàn àlọ́ jẹ́, kì í ṣe ìṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá ìhun ìtàn tí ó wà nínú àlọ́. Àwọn ni: àyípadà ìgbà, àṣeṣetúnṣe, ìṣẹ̀lẹ̀ àyísódì, ìrànlọ́wọ́ àti ibùdó ìṣẹ̀lẹ̀. Àwọn àbùdá yìí ni àwọn ọ̀nà tí a fi ń gbé ìtàn kalẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

(a) Kí ni ìtumọ̀ àhunpọ̀-ìtàn?

(b) Ṣe àlàyé lórí àwọn àbùdá ìhun ìtàn yìí:

(i) àyípadà ìṣẹ̀lẹ̀

(ii) ìrànlọ́wọ́

(iii) ibùdó-ìṣẹ̀lẹ̀

(iv) àṣeṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀

(v) àyípadà ìgbà

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn àlọ́ onítàn.* Ibadan: Y – Books.

Ogundeji, P.A. (1991) *Introduction to Yoruba Oral Literature*. *(Ìfáárà sí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá).*External Studies Programme.Adult Education Department, University of Ibadan.

Ògúnpolú, I.B. (1989) "Tíọ́rì Ìgbétànkalẹ̀ Láwùjọ: Ìlànà Ọ̀tun Láti Ṣe Àtúpalẹ̀ Lítíréṣọ̀ Yorùbá" *Sẹmina ni Ìrántí J.S.A. Odujinrin.* Lagos. Dept. of Nigerian Languages and Literatures, Ogun State University, Agọ Iwoye, pp. 283 – 294.

# ÌPÍN KẸTA: Ẹ̀DÁ-ÌTÀN ÀTI ÌFÌWÀWẸ̀DÁ

## Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.1 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.2 Ìtumọ̀ ẹ̀dá-ìtàn
4.3 Ìfìwàwẹ̀dá
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Lábẹ́ ìpín yìí, àwọn ohun tí a ó yẹ̀wòniìtumọ̀ ẹ̀dá-ìtàn, oríṣi ẹ̀dá-ìtàn àti aáyan ìfìwàwẹ̀dá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ le ṣàlàyé:

(a) ìtumọ̀ ẹ̀dá-ìtàn
(b) oríṣi àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú àlọ́ onítàn
(d) ìtumọ̀ ìfìwàwẹ̀dá àti aáyan ìfìwàwẹ̀dá

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Fún wa ní àpẹrẹ àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú àlọ́.
2. Irú ẹ̀dá-ìtàn wo ni ìjàpá?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Ìtumọ̀ ẹ̀dá-ìtàn

Àwọn tí ó kópa nínú àlọ́ onítàn ni à ń pè ní ẹ̀dá-ìtàn. Ìsọ̀rí ẹ̀dá-ìtàn mẹ́ta ló wà nínú àlọ́ onítàn. Ìsọ̀rí kínní ni àwọn ènìyàn (ẹ̀dá). Ìsọ̀rí kejì ni àwọn ẹranko. Ẹ̀kẹta sì ni àwọn ẹ̀dá míriyìírí. Lábẹ́ ìsọ̀rí ènìyàn, lábẹ́ ẹranko àti ẹyẹ ni a ti rí àdàbà, ẹyẹlé, ọ̀nì, erin, ehoro àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Lábẹ́ àwọn ohun míríyìírí sì ni àwọn iwin, òrìṣà, òkú àti àjẹ́. Àwòrán onígi ìsàlẹ̀ yìí yóò túbọ̀ jẹ́ kí àlàyé tí à ń ṣe yé ọ.




Àjọṣepọ̀ àti ìbáṣepọ̀ máa ń wà láàrin [illegible] ìí paapaa láàrin ènìyàn àti ẹranko.Èyí wọ́pọ̀ nínú àlọ́ ìjàpá. Fún àpẹẹrẹ nínú ìtàn 'Ìjàpá àti Ìyá Alákàrà' (Babalọla 1979: 20 – 25), a rí àpẹẹrẹ ìbágbépọ̀ àti ìbáṣepọ̀ láàrin ẹranko àti ènìyàn. Lára àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú ìtàn yìí ni: Ìjàpá, Ìyá Alákàrà, Omidan kan (ọmọ-alákàrà), ọba, àwọn ọdẹ, babaláwo, ọ̀sanyìn-ẹlẹ́sẹ̀ kan àti àwọn ìjòyè.

Kì í ṣe ní gbogbo ìgbà ni àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú ìtàn àlọ́ máa ń jẹ́ orúkọ gidi. Yàtọ̀ fún àwọn ẹranko, ẹyẹ àti igi àti àwọn ohun mìíràn tí kò ní ẹ̀mí ṣùgbọ́n tí wọ́n ní orúkọ bí i àpáta, òjò, omi, abbl.Àwọn ènìyàn inú àlọ́ kì í ní orúkọ pàtó. Irú iṣẹ́ tí wọn ń ṣe tàbí ipò tí wọ́n wà ní a fi ń pè wọ́n. Fún àpẹẹrẹ: Ọba, Ìjòyè, Ìyá-alákàrà, Ọdẹ, Àgbẹ̀, Bàbá-Ẹlẹ́mu, ọ̀rẹ́ Alábahun, ọmọ-ọba, ìyàwó, ìyáálé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Yánníbo, ìyàwó Ìjàpá ni ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ ẹni tí a fún lórúkọ.

## 4.2 Ìfiwàwẹ̀dá

Ó yẹ kí á ṣàlàyé pèìfiwàwẹ̀dá yàtọ̀ sí ẹ̀dá-ìtàn.Ìfiwàwẹ̀dá ni àwọn ọgbọ́n tí òǹkọ̀wé lò láti mú kí àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú iṣẹ́ ọnà rẹ̀ ní àwòmọ́ ènìyàn tàbí ìwà tí òǹkọ̀wé gbé wọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀. Lóòótọ́ a kò lè sọ ní pàtó pé òǹkọ̀wé báyìí báyìí ni ó kọ ìtàn, àlọ́, ṣùgbọ́n ìtumọ̀ ìfiwàwẹ̀dá yìí náà bá ti ẹ̀dá-ìtàn inú àlọ́ mu.

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jé káári-ayé, ohun márùn-ún ni a lè fi ṣe ìtúpalẹ̀ ìwà ẹ̀dá-ìtàn inú ìtàn kan:

(i) ohun tí asọ̀tàn sọ nípa ẹ̀dá-ìtàn
(ii) ohun tí àwọn ẹ̀dá-ìtàn yòókù sọ nípa rẹ̀
(iii) ohun tí ẹ̀dá-ìtàn náà bá sọ nípa ara rẹ̀
(iv) ìṣesí àti ìhùwàsí ẹ̀dá-ìtàn náà.
(v) ìrísí àti orúkọ ẹ̀dá-ìtàn náà.

Ohun tí asọ̀tàn bá sọ nípa ẹ̀dá-ìtàn ṣe pàtàkì púpọ̀ láti júwe irú ènìyàn tí ẹ̀dá-ìtàn náà jẹ́. Bákan náà ni ohun tí àwọn ẹ̀dá-ìtàn yòókù bá sọ nípa ẹ̀dá-ìtàn kan náà ṣe pàtàkì láti ṣe àpèjúwe irú ẹni tí ẹ̀dá-ìtàn náà jẹ́. Nígbà mìíràn, ẹ̀dá-ìtàn kan lè ṣe àpèjúwe ara rẹ̀. Èyí náà tún máa ń jẹ́ kí á mọ irú ènìyàn tí ẹ̀dá-ìtàn náà jẹ́. Ìṣesí àti ìhùwàsí ẹ̀dá-ìtàn kan náà máa ń ràn wá lọ́wọ́ láti mọ irú ẹni tí ó jẹ́. Fún àpẹẹrẹ ìwà Ìjàpá nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìtàn àlọ́ ìjàpá jẹ́ kí a lè sọ irú ẹ̀dá-ìtàn tí Ìjàpá jẹ́.Àwọn ìwà bí olè jíjà, ojúkòkòrò, àìnítẹ̀lọ́rùn, irọ́ pípa àti àwọn ìwà búburú mìíràn tí Ìjàpá ń hù ní à ń lò láti ṣe àpèjúwe rẹ̀. Gbogbo akitiyan yìí ni à ń pè ní ìfìwàwẹ̀dá.

Ní ìgbẹ̀yìn, a lè lo ìrísí tàbí orúkọ ẹ̀dá-ìtàn láti ṣe àpèjúwe rẹ̀.Fún àpẹẹrẹ orúkọ àti ìnagijẹ tí a fún Ìjàpá jẹ́ kí á mọ irú ẹ̀dá-ìtàn tí ó jẹ́ – 'Ìjàpá ọlọ́gbọ́n-ẹ̀wẹ́', 'Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo'. Oríkì ìjàpá nínú àwọn àlọ́ onítàn náà júwe ìrísí rẹ̀:

Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo
Ẹsẹ̀ danindanin bí àran ọ̀pẹ
Tó kọ́lékọ́lé, tó fi ìrán bà á jẹ́
Tí ń lọ láàrin ẹ̀pà, típàkọ́ rẹ̀ ń hàn fírífírí
Ó ní ọpẹ́lọpẹ́ pé òun ga!

Nínú oríkì yìí, a lè júwe ìrísí Ìjàpá báyìí: Ó jẹ́ ẹranko tàbí èdá-ìtàn tí ẹsẹ̀ rẹ̀ yí bí i àran ọ̀pẹ, ẹ̀dá-ìtàn tó ní igbá lẹ́yìn àti ìrán ní ìdí rẹ̀. Ìlà méjì tí ó gbẹ́yìn jẹ́ kíá mọ̀ pé ẹranko tàbí ẹ̀dá-ìtàn kúkurú, tí kò ga ni Ìjàpá.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àgbéyẹ̀wò ìtumọ̀ àti oríṣi ẹ̀dá-ìtàn tó wà. Ìsọ̀rí mẹ́ta ni a pín àwọn ẹ̀dá-ìtàn sí: ènìyàn, ẹranko àti ẹyẹ àti ẹ̀dá mérìíyìírí. Bákan náà, ni a ṣe àgbéyẹ̀wò ohun tí ìfìwàwẹ̀dá jẹ́ àti àwọn ọ̀nà tí a lè lò láti ṣe àpèjúwe ẹ̀dá-ìtàn kan tàbí irú ẹni tí ó jẹ́.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ṣàlàyé lórí irú àwọn ẹ̀dá-ìtàn tó wà nínú àlọ́ onítàn.
2. Kí ni ìtumọ̀ ìfìwàwẹ̀dá?
3. Àwọn ohun márùn-ún wo ni a lè lò láti fi ṣàpèjúwe ẹ̀dá-ìtàn kan?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ogundeji, P.A. (1991) *Introduction to Yoruba Oral Literature*. *(Ìfáárà sí Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá)*.External Studies Programme.Adult Education Department, University of Ibadan.Dasylva, A. O.

(2017) "Folklore, Oral Traditions and Oral Literature" in Toyin Falọla and Akintunde Akinyẹmi (ed.) Culture and Customs of the Yo-ruba.USA Pan-African University press, pp. 139 – 158.

# MÓDÙ KẸTA: ÌLÒ ÈDÈ ÀTI BÁTÀNÌ GBÓLÓHÙN ÌṢÍDE ÀTI ÌPARÍ ÀLỌ́

## Àkóónú Ìpín kínní: Ìlò Èdè

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Àfiwé tààrà
    4.2 Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́
    4.3 Ìfohunpènìyàn/Ìsọhundènìyàn
    4.4 Àsọdùn/Asọrégèé
    4.5 Ìfìrómọ̀rísí/Ìfìrógbóyeyọ
    4.6 Àwítúnwí
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Ní abẹ́ Módù yìí ni a ó ti ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀nà ìṣọwọ́loèdè inú àlọ́ àti àwọn bátànì ìṣíde àti ìparí àlọ́. Bátànì ìlò èdè nínú àlọ́ ni ìṣíde àti ìparí àlọ́ jẹ́.

Ìpín kínní: Ìlò Èdè
Ìpín kejì: Bátànì Gbólóhùn Ìṣíde Àlọ́
Ìpín kẹta: Bátànì Gbólóhùn Ìparí Àlọ́
Ìlò èdè jẹ́ ohun pàtàkì tí kò ṣe é fojú fò rárá nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọ̀nà

lítíréṣọ̀ kan bí i àlọ́ onítàn. Lílo èdè tó dára máa ń jẹ́ kí ìtàn múnilọ́kàn gidi. Èdè ni ó ń mú ìtàn dùn nínú àlọ́ yòówù tí apàlọ́ fẹ́ pa.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o gbọ́dọ̀ mọ:
1. ohun tí ìlò èdè jẹ́
2. díẹ̀ lára àwọn ọ̀nà èdè tó jẹyọ nínú àlọ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kí ni ìlò-èdè?
2. Fún wa ní àpẹẹrẹ ọ̀nà-èdè mẹ́ta.

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Àfiwé Tààrà

Ọnà èdè yìí máa ń jẹyọ púpọ̀ nínú àlọ́. Ohun méjì tó jọra ni a fi ń wé ara wọn nínú àfiwé tààrà. Ìjọra yìí lè jẹ́ nípa ìrísí, ìrírí àti ìhùwàsí. Àfiwé tààrà ní àwọn ọ̀rọ̀ kan tí ó ń ṣe atọ́ka rẹ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ náà ni: bíi, bí, tó. Àwọn ọ̀rọ̀ yìí jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń fi ìrísí hàn.

Nínú ìtàn Ìjàpá àti Àwọn Èrò Ọjà (Ọ̀pádọ̀tun 1994: 80 – 83) a rí àpẹẹrẹ àfiwé tààrà níbẹ̀:

(i) Àwọn ọmọ lòun tún bẹ̀rẹ̀ sí pa sílẹ̀ bí ìdin yìí (o.i. 80). Èyí túmọ̀ sí pé àwon ọmọ Ìjàpá pọ̀ bí ìdin ṣe ń pọ̀.

(ii) 'Oníkálùkù bá gba orin náà bí ẹni gba igbá ọtí (o.i. 82).
Ní ayé àtijọ́ níṣe ni à ń gbé igbá ọtí kiri. Bí ẹni kan bá ti mu ọtí tàbí ẹmu nínú igbá yóò gbé e fún ẹni tí ó tẹ̀lé e.
Nínú ìtàn 'Ìjàpá àti Àdàbà jọ dá oko kan' a rí àfiwé tààrà níbi tí asọ̀tàn ti ń ṣe àpèjúwe bí oko tí Ìjàpá àti Àdàbà jọ dá ṣe tóbi tó.

(iii) Oko yẹn kàn lọ gbansasa bí omi òkun ni
Nínú ìtàn 'Ìjàpá àti Àgàràmọ̀kù (Babalọla, 1979: 8).

(iv) Ó ń fahọ́n pọ́n nu béré bíi ejò (o.i. 7).

## 4.2 Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́

Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ náà ni à ń pè ní 'mẹ́táfọ̀'. Àfiwé inú ọnà èdè yìí kò lọ tààrà bíi ti àfiwé tààrà. Ìjọra tí ó dálé orí ìhùwàsì àti ìrísí náà gbọ́dọ̀ wà nínú ohun méjì tí a fi ń wé ara wọn. Fún àpẹẹrẹ tí a bá ní:

(i) Ajá ni ọmọ náà

Ohun tí à ń ṣe ni pé, à ń fi ìwà ọmọ náà wé ti ajá. Èyí ni pé ọmọ náà ń ṣe ìṣekúṣe.

Nígbà mìíràn, ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ ni ó máa ń jẹ́ kí á mọ ìtumọ̀ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ nítorí pé àfiwé kan lè ní ju ìtumọ̀ kan lọ. Fún àpẹẹrẹ:

(ii) Ẹlẹ́dẹ̀ ni obìnrin náà

Ìtumọ̀ èyí pín sí ọ̀nà mẹ́ta. Ọ̀nà kínní ni pé, ọ̀bùn ni obìnrin náà. Èkejì sì ni pé obìnrin náà bímọ púpọ̀ bí ẹlẹ́dẹ̀. Ìkẹta ni pé ó ní inú fùfù (ìbínú àbíjù).

Àwọn onímọ̀ kan tilẹ̀ sọ pé àfidípò (metonymy) ní àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ jẹ́ nítorí à ń fi ohun kan di ohun mìíràn. Fún àpẹẹrẹ nínú oríkì Yorùbá, a lè fi ìnagijẹ dípò orúkọ ẹnìkan.

(iii) Adéyẹmí Alówólódù

Nínú àpẹẹrẹ yìí, Alówólódù le è rọ́pò Adéyẹmí. Bí a bá ti pè é, a á mọ̀ pé òun (Adéyẹmí) ni à ń pè.
Àpẹẹrẹ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí àfidípò náà pọ̀ nínú àlọ́ àpamọ̀ àti òwe Yorùbá
Àpẹẹrẹàfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ wà nínú ìtàn 'Ìjàpá ká ehín Erin'.

(iv) kàkà kí ewé àgbọn rọ̀, líle ni ń le sí i. (o.i. 36)

Àpẹẹrẹ yìí náà jẹ́ òkan nínú òwe Yorùbá. Ṣùgbọ́n àìsàn baba Yánníbo, ìyàwó Ìjàpá ni a fi ń wé ewé àgbọn nínú òwe yìí.

(v) egungun-náín-ẹran-tọ́rọ́ ni (o.i. 36)

Àfiwé yìí ń ṣe ìrísí baba Yánníbo nígbà tí ó ń ṣàìsàn. Ìtumọ̀ èyí ni pé ó rù gidi; kò lẹ́ran lára.

(vi) '<u>Abokorẹrẹ</u> ni àwọn ará àdúgbò máa ń pe gbogbo wọn'

Àpẹẹrẹ yìí jẹ mọ́ àpẹẹrẹ (iii) lókè. Nítorí pé àwọn ọ̀rẹ́ mẹ́fà (Ejò, Ẹmọ́, Àfè, Ẹdá, Ẹ̀lírí àti Ẹgbárá) inú àlọ́ yìí jẹ́ àgbẹ̀ tí oko wọn sì tóbi, àwọn ènìyàn fún wọn ní ìnagijẹ yìí, èyí tí ó di orúkọ wọn. Nínú ìtàn 'Ìdí tí Ejò fi ń pa Eku jẹ' ni a ti mú àpẹẹrẹ yìí (Ọ̀pádọ̀tun 1994: 12).

## 4.3 Ìfohunpènìyàn/Ìsọhundènìyàn

Kí á gbé ìwà, ìhùwàsí tàbí ìrísí ènìyàn wọ ohun tí kì í ṣe ènìyàn ni à ńpè ní ìfohunpènìyàn. Nínú ọnà-èdè yìí ni ohun tí kì í ṣe ènìyàn tàbí ohun tí kò lẹ́mìí ti ń hùwà ènìyàn kan tàbí ní àbùdá ènìyàn. Ọnà èdè yìí ni àwọn mìíràn náà ń pè ní Ìsọhundènìyàn. Ọlábọ̀dé (1992: 42) tilẹ̀ ṣe àkójọpọ̀ lilo "ẹ̀yà ara ènìyàn láti tọ́ka sí ohun tí kì í ṣe ènìyàn. Àwọn òkú ìsọhundènìyàn ni Ọlábọ̀dé pe àwọn àpẹẹrẹ yìí nítorí pé wọ́n ti di bárakú nínú èdè Yorùbá:

Orí <u>igi</u>
Ẹnu<u>ọ̀nà</u>
Etí <u>odò</u>
Ojú <u>ilẹ̀</u>

Gbogbo àwọn ohun aláìlẹ́mìí tí kì í ṣe ènìyàn tí a fa ìlà sí lókè yìí ni wọ́n ní àbùdá ènìyàn tí a fi ń ṣe àpèjúwe wọn. Àpẹẹrẹ ìfohunpènìyàn tàbí ìsọhundènìyàn náà pọ̀ nínú àlọ́ onítàn:

(i) 'Àpáta yìí tẹ́jú'
(ii) 'Ọ̀gbẹ́ni Àpáta'
(Babalọla, 1979: 6)
(iii) Ó bá wọlé, ó sán ṣòkòtò rẹ̀, ó gbé igbá rẹ̀, ó mú àdá rẹ̀.
(Babalọlá 1979: 29)

Ìjàpá ni ó ṣe bí ènìyàn nínú àlọ́ 'Ìjàpá àti Àbọ̀n-ẹyìn'.

Nínú àlọ́ ìjàpá, gbogbo àwọn ẹranko mú àwọn àlọ́ yìí ni ó ń hùwà bí ènìyàn. Wọ́n ń sọ̀rọ̀, wọ́n ń ní ìtàkurọ̀sọ, wọ́n ń ní ọba, wọ́n ń ní ìdílé àti bẹ́ẹ̀ lọ, àwọn ẹbọra ń sọ̀rọ̀, ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀ kan, méjì, mẹ́fà wà. Fún ìdí èyí, a lè sọ pé ìsọhundènìyàn ni ó jẹ́ kókó ọnà-èdè inú àlọ́ onítàn.

## 4.4 Àsọdùn/Àsọrégèé

Gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ tí à ń pe ọnà-èdè yìí, sísọ àsọdùn ni ó rọ̀mọ́. A lè sọ pé ọnà-èdè yìí rọ̀mọ́ ohun tí Yorùbá ń pè ní à-sọ-ré-kọjá-ewé. Jíjúwe ìṣẹ̀lẹ̀ kan tàbí ohun kan tí kò le ṣẹlẹ̀, ṣùgbọ́n tí ó lè mú ìtàn kan dùn.

Àpẹẹrẹ ọnà-èdè yìí pọ̀ nínú àlọ́ onítàn. Ẹ jẹ́ kí á wo àyọlò yìí nínú 'Ìtàn Ìjàpá àti Àgàràmọ̀kì':

(i) Ìjàpá gbé Àgàràmọ̀kù délé Ọba; ó sọ̀ ọ́ kalẹ̀. Àgàràmọ̀kù ní kí wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í se oúnjẹ fún òun; wọ́n bẹ̀rẹ̀, wọ́n ń sè, wọ́n ń sọ̀, gbogbo ẹran tó wà nílùú: ewúrẹ́, àgùntàn, adìẹ, pẹ́pẹ́yẹ, àgbò, òbúkọ, ẹranńlá, gbogbo rẹ̀ ni wọ́n sè fún Àgàràmọ̀kù, ó sì ń jẹ wọ́n. Agàràmọ̀kù rè é, kì í yó; bó ti ń jẹ bẹ́ẹ̀ ló ń ṣu, ló ń tọ̀.
(Babalọlá, 1979: 11)

A rí i nínú àyọlò yìí pé àsọdùn wà níbẹ̀. Ìbéèrè tó lè wá sí ọkàn wa ni pé: Ǹjẹ́ èyí lè ṣẹlẹ̀ kí ẹnìkan jẹ gbogbo ẹran yìí tán? Àsọdùn ni èyí jẹ́, ṣùgbọ́n ó mú ìtàn náà dùn.

(ii) Bákan náà nínú ìtàn Ìjàpá àti Ìyá Ẹlẹ́pà a rí àsọdun:

Lẹ́yìn èyí, Ọba ránṣẹ́ pe gbogbo àwọn irúnmọlẹ̀ ìlú. Nígbà tí àwọn imọlẹ̀ náà dé iwájú Ọba, Ọba bẹ̀ wọ́n pé ó kàn wọ́n, ó kan àgbàágbà, pé lọ́jọ́-ọjà ijọ́ mẹ́rin òní, wọn ó bá òun mú olè afiniṣẹ̀sín náà. Ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀mẹ́wàá wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́sàn-án wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀mẹ́jọ wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀méje wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀mẹ́fà wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀ márùn-ún wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin wà ń bẹ̀; ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́ta wà ń bẹ̀;
(Babalọla 1973: 5)

## 4.5 Fìrómọ̀rísí

Àpẹẹrẹ fìrómọ̀rísí tàbí fìrógbóyeyọ̀ pọ̀ nínú àlọ́ onítàn.A ó ṣe àyẹ̀wò díẹ̀. Nínú ìtàn 'Ìjàpá àti Àdàbà jọ dá oko kan' ni a ti rí àpẹẹrẹ yìí:

(ix) Àwọn ọ̀rẹ́ méjì yìí wá jọ dá oko kan, oko yìí tó ibùsọ̀ méjì ní ìbú, ó tó ibùsọ̀ mẹ́ta ní ìró. Oko yẹn kàn lọ gbansasa bí omi òkun ni. Wọ́n wá gbin oríṣiríṣi ohun tí ẹnu ń jẹ sínú rẹ̀: iṣu lọ salalu, gbogbo rẹ̀ ta bọ̀kùàbọ̀kùà, wọ́n san ebè kẹ́rẹkẹ̀rẹ bí ẹ̀gbẹ́ ọ̀giri ògbólógbòó ilé; ẹ̀gẹ́ ta fálafàla; àgbàdo gbọ́mọpọ̀n dọ̀ǹkùdọnku, ewébẹ̀ lọ súà bí i koríko inú pápá, wọ́n dúdú minrinminrin bí ewéko etípadò, gbogbo ohun ọ̀gbìn wọn ṣe dáradára.

(Babalọlá 1973: 8)

(x) Akèǹgbè rún wómúwómú – p. 19
(xi) Ilẹ̀ ń ró gìrìgìrì, gbogbo igi igbó ń mì rìyàrìyà –p. 22
(xii) wọ́n ṣèèṣì tẹ ìgbákọ mọ́lẹ̀, ó fọ́ pẹ́kẹpẹ̀kẹ –p. 34

## 4.6 Àwítúnwí

Oríṣi àwítúnwí méjì ló wà. Àwọn ni: àwítúnwí ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ àti àwítúnwí oníhun gbólóhùn. Ṣùgbọ́n a lè ṣe àtúnpín oníhun gbólóhùn sí ọ̀nà méjì: àwítúnwí àpólà gbólóhùn àti àwítúnwí odidi gbólóhùn. A lè lo àwòrán onígi láti jẹ́ kí òye yìí túbọ̀ yéwa yékéyéké:

Àwítúnwí

Ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ Oníhun gbólóhùn

Àpólà gbólóhùn Odindi gbólóhùn

A ó wo àpẹẹrẹ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn oríṣi àwítúnwí yìí bí wọ́n ṣe jẹyọ nínú àlọ́.

(i) Àwítúnwí Ẹlẹ́yọ Ọ̀rọ̀

(a) onígbà mú igbá, onífe mú ife
(b) Ọ̀pá, Afúnmọ-lára-bí-ọyẹ́, Ọ̀pá, Ọ̀gbọ̀n-rírì-hara-ọmọ-nù
(d) Ó fìyà jẹ ọkùnrin, ó fìyà jẹ obìnrin; tọmọge-tadélébọ̀ ló jìyà ló jewé ìyà pẹ̀lú. (Babalọlá 1973: 35 – 36)

(ii) Àwítúnwí Àpólà Gbólóhùn

(a) Ọmọ-ọwọ́ kì í kú lójú ọwọ́, bẹ́ẹ̀ ni ọmọ-ẹsẹ̀ kì í kú lójú ẹsẹ̀, àwọn ọmọ rẹ̀ kò ní kú lójú rẹ.
(b) Dájúdájú wọ́n ń rí bìkan bá wọ̀ ọ́, wọ́n ń ríkan ṣè kan.
(d) Nígbà tí wọ́n dé oko, Ìjàpá bẹ̀rẹ̀ sí í wa iṣu, ó wà kínní, ó wà kejì, ó wà kẹta, ó wà á títí mẹ́fà pé. (Babalọlá 1973: 39 – 41)

(iii) Àwítúnwí Gbólóhùn

Àpẹẹrẹ àwítúnwí gbólóhùn kún inú orin àlọ́ fọ́fọ́. Ó fẹ́rẹ̀ má sí ì orin àlọ́ kan tí kò ní i nínú. Nínú orin ìtàn Ìjàpá àti Ajá lọ jí iṣu wà, a rí àpẹẹrẹ ọnà-èdè yìí:

Lílé: Ajá ó, ràn mí lẹ́rù,
Ègbè: Ṣémbélékeṣé
Lílé: Ajá ó, ràn mí lẹ́rù,
Ègbè: Ṣémbélékeṣé
Lílé: Bó ò bá ràn mi lẹ́rù, má ké s’Ólóko,
Ègbè: Ṣémbélékeṣé
Lílé: Bólóko gbọ́ o, a mú ọ dè.
Ègbè: Ṣémbélékeṣé
Lílé: A mú ọ dè, á gbà ọ níṣu,
Ègbè: Ṣémbélékeṣé
Lílé: Ajá ó, ràn mí lẹ́rù,
Ègbè: Ṣémbélékeṣé

Nínú orin àlọ́ òkè yìí, èyí tí ó ní àbùdá lílé àti ègbè, a rí àpẹẹrẹ àwítúnwí gbólóhùn nínú lílé àti àwítúnwí ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ nínú ègbè. Gbogbo orin inú àlọ́ ni ó ní bátànì yìí. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ mìíràn. A mú àpẹrẹ yìí láti inú ìtàn 'Ìjàpá àti Bùje' (Babalọlá 1973: 161 – 166):

Bùjé, Bùje pa mi o,
Terebùjé
Bùjé, Bùje pa mi o,
Terebùjé
Oko mi mò ń ro
Terebùjé
Ọ̀nà mi mò ń yẹ̀,
Terebùjé
Bùjé ni n wá yà p'ejò
Terebùjé
Ò pejò pojúgun
Terebùjé
Ò bẹ̀rẹ̀ gb'Áhun pọ̀n
Terebùjé
Ò gbáhun pọ̀n, gb'Áhun jó
Terebùjé
Gbé mi síbàdí ká re lé
Terebùjé
Ìbàdí layé wà
Terebùjé
Ìbàdí layé wà
Terebùjé

Gbogbo oríṣi àwítúnwí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a ti mẹ́nubà lókè yìí ni ó jẹyọ nínú orin yìí. bí a ti rí àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ pàápàá nínú ègbè orin yìí, ni a rí àwítúnwí àpólà gbólóhùn ní ìlà 5, 7, 13, 15. Àwítúnwí gbólóhùn ni a rí ní ìlà 1, 3, 19 àti 21.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìpín yìí, a ti ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò-èdè nínú àlọ́ onítàn àti oríṣiríṣi ọnà-èdè tó jẹyọ àti àpẹẹrẹ wọn. Lára àwọn ọnà-èdè tí a rí fàyọ nínú àlọ́ onítàn ni àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, ìfohunpènìyàn tàbí ìsọhun dènìyàn, àsọdùn tàbí àsọrégèé, fìrómọ̀rísí tàbí fìrógbóyeyọ, àti àwítúnwí.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ipa wo ni èdè ń kó nínú ìtàn?
2. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé àpẹrẹ lórí àfiwé tààrà nínú àlọ́ kan tí o kà.
3. Kí ni àwọn àbùdá inú ìfọ̀rọ̀dárà?
4. Ṣàlàyé lórí ìfohunpènìyàn tàbí ìsọhundènìyàn pẹ̀lú àpẹẹrẹ láti inú àwọn àlọ́ tí o ti kà.
5. Wá àlọ́ kan tí ó ní àsọdùn tàbí àsọrégèé kí o sì ṣe àtúpalẹ̀ ọnà-èdè náà.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Babalọlá, A. (1973) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá,* Apá Kínní. Ibadan: University Press Ltd.

Babalọlá, A. (1979) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá,* Apá Kejì. Ibadan: University Press Ltd.

Ọlábọ̀dé, A. (1992) *LIY 371: Ìmọ̀ Ìṣọwọ́loèdè Yorùbá*. University of Ibadan. External Studies Programme.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ibadan: Y-Books.

# ÌPÍN KEJÌ: BÁTÀNÌ GBÓLÓHÙN ÌṢÍDE ÀTI ÌPARÍ ÀLỌ́ ÀKÓÓNÚ

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní abẹ́ ìpín yìí,a ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọnà èdè tó jẹyọ nínú bátànì gbólóhùn ìṣíde àti ìparí àlọ́.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o gbọ́dọ̀ le mọ:

1. àwọn oríṣiríṣi bátànì ìṣíde àti ìparí àlọ́.
2. àwọn ọnà-èdè tó jẹyọ nínú àwọn bátànì yìí.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ọ̀nà wo ni à ń gbà ṣíde àlọ́?
2. Bátànì wo ni à ń lò parí àlọ́?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Bátànì Gbólóhùn Ìṣíde Àlọ́

Oríṣi ìtàkurọ̀sọ ni ó máa ń wáyé láàrin apàlọ́ àti àwọn olùgbọ́ rẹ̀ tí ó jẹ́ àwọn ọmọdé. Lílo ète ìtàkurọ̀sọ yìí wà fún ìtanijí àwọn ọmọdé yìí àti láti mú wọn jẹ́ akópa nínú ìtàn náà. Àpẹẹrẹ àwọn ìṣíde yìí ni a ó rí ní ìsàlẹ̀ yìí:

**Ọ̀nà ìṣídé – 1**

Apàlọ́: Àálọ́ o!......
Àwọn ọmọdé: Àálọ̀
Apàlọ́: Ní ọjọ́ kan…
Àwọn ọmọdé: Ọjọ́ kan kì í tán láyé …….
Apàlọ́: Ní ìgbà kan
Àwọn ọmọdé: Ìgbà kan ń lọ, ìgbà kan ń bọ̀, ọjọ́ ń gorí ọjọ́.
Apàlọ́: Ní ìlú Ìjàpá ………..

Nínú ìṣíde yìí, a rí àpẹẹrẹ ìsọ̀rọ̀ǹfèsì láàrin apàlọ́ àti àwọn olùgbọ́ rẹ̀ (àwọn ọmọdé). Ọnà èdè kan tí ó wọ́pọ̀ jùlọ nínú ìṣíde àlọ́ yìí ni àwítúnwí. Bí a ṣe rí àpẹẹrẹ àwítúnwí ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ni a rí àpẹẹrẹ àwítúnwí àpólà gbólóhùn.

Ní ìlà kínní àti èkejì ni a ti rí àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀. Ìlà 4 – 5 (àpólà gbólohùn), 6 – 7 (àpólà gbólóhùn). Ní ìlà 1 – 2, a rí ìyàtọ̀ nínú ohùn orí sílébù ìlà 2 èyí tí ó sì mú kí ọnà èdè ìfọ̀rọ̀dárà jẹyọ.

**Ọ̀nà ìṣíde àlọ́ – 2**

| | |
|---|---|
| Apàlọ́: | Ààló o!...... |
| Àwọn ọmọdé: | Ààlọ̀ |
| Apàlọ́: | Bàbá kanwà |
| Àwọn ọmọdé: | Ó wà bí ẹ̀wà |
| Apàlọ́: | Óbí ọmọ kan |
| Àwọn ọmọdé: | Óbí i, bí i, bí i |
| Apàlọ́: | Kò rí bí |

Nínú ìṣíde yìí náà ni a ti rí àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ àti àpólà. Ìlà 1 àti 2 (àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀) Ìlà 3 àti 4 (àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀) ìlà 5 àti 6 (àwítúnwí àpólà gbólóhùn).

Nínú àlọ́ oríṣiríṣi ọnà èdè ni a lè rí àwọn ọnà èdè bí i àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àwítúnwí, ìfọ̀rọ̀dárà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ó fa àwọn àpẹẹrẹ ọnà èdè yọ nínú àwọn àlọ́ tí a ó rí ní Módù karùn-ún àti ẹ̀kẹfà.

**Ọ̀nà ìṣíde àlọ́ – 3**

| | |
|---|---|
| Apàlọ́: | Ààlọ́ o!...... |
| Àwọn ọmọdé: | Ààlọ̀ |
| Apàlọ́: | Àlọ́ mi dá firìgbágbòó, ó dáléri Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo, Àtíòro, Yemọja, Ọ̀nì àti Ẹkùn. |

Ìṣíde yìí kò gùn tó méjì àkọ́kọ́ nítorí ìgbésẹ̀ mẹ́ta péré ló ní. Ní ìlà 1 àti 2 ni a ti rí àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀.

Nítorí pé àlọ́ onítàn kò ní ìgbà àti àkókò kan pàtó tí a dá a sílẹ̀, àwọn ìpèdè bí i 'Ní ìgbà kan', Ní ọjọ́ kan', 'Ní ìgbà láéláé', 'Ní ayé àtijọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni à ń lò láti bẹ̀rẹ̀ ìtàn àlọ́.

## 4.2 Bátànì Gbólóhùn Ìparí Àlọ́

Bí ó ṣe wà nínú ìṣídé àlọ́, bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn bátànì ìlò èdè wà fún ìparí àlọ́. Lẹ́yìn tí apàlọ́ bá fi sọ ọgbọ́n tí ó fẹ́ kí àwọn ọmọdé kọ́ nínú àlọ́ ni yóò sọ báyìí pé:

Apàlọ̀: Ìdí àlọ́ mi rè é gbáńgbáláká
Ìdí àlọ́ mi rè é gbàǹgbàlàkà
Bí n bá purọ́ kí agogo ẹnu mi má rò ó
Ṣùgbọ́n bí n ò bá purọ́, kí agogo ẹnu mi ró lẹ́ẹ̀mẹta
Ó di pó… pò…pó!
Àwọn ọmọdé: Ẹ ò purọ́ baba

Apàlọ́ máa ń lo bátànì ìlò èdè yìí láti jẹ́ kí àwọn ọmọdé rò pé òótọ́ ni ìtàn àlọ́ yìí ṣẹlẹ̀. Nítorí pé àlọ́ jẹ́ ìtàn àtinúdá tí à ń pa fún àwo ọmọdé láti dá wọn lẹ́kọ̀ọ́, apàlọ́ máa ń gbìyànjú láti mú kí àwọn ọmọdé máa rò pé ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi ni. Ìdí ni èyí tí apàlọ́ yóò ki ọwọ́ bọ inú ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀ lẹ́ẹ̀mẹta láti jẹ́ kí ó ró. Èyí ni apàlọ́ ń pè ní agogo ẹnu. Èyí ni ó sì fi òte lé e pé òótọ́ ni ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn náà. Ìdí sì ni èyí tí àwọn ọmọdé náà yóò fi pariwo pé 'Ẹ ò purọ́ baba'.

Nínú bátànì ìparí àlọ́ yìí ni a ti rí àwọn ọnà èdè wọ̀nyí: àwítúnwí gbólóhùn (ìlà 1 & 2) ìfọ̀rọ̀dárà – ìlà 1 àti 2 (gbáńgbáláká/gbàǹgbàlàkà), àwítúnwí àpólà gbólóhùn (ìlà 3 àti 4).

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àyẹ̀wò ìlò èdè nínú àlọ́ pàápàá àwọn tó wà nínú bátànì gbólóhùn tí a fi ń ṣíde àlọ́ àti èyí tí a fi ń parí àlọ́. A ti wo oríṣiríṣi ìtàkurọ̀sọ tí ó máa ń wáyé láàrin apàlọ́ àti àwọn olùgbọ́ rẹ̀. A rí àpẹẹrẹ àwọn ọnà èdè wọ̀nyí nínú bátànì gbólóhùn ìṣíde àti ìparí àlọ́: àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀, àwítúnwí àpólà gbólóhùn, ìfọ̀rọ̀dárà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Fún wa ní ó kéré tán àpẹẹrẹ ìṣíde àlọ́ méjì.
2. Àwọn ọnà èdè wo ni o rí fàyọ nínú àwọn ìṣíde àlọ́ náà?
3. Bátànì gbólóhùn wo ni a fi ń parí àlọ́?
4. Ṣe àpèjúwe àwọn ọnà èdè inú bátànì yìí.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ibadan: Y-Books.

# MÓDÙ KẸRIN: ÀTÚPALẸ̀ ÀWỌN ÀṢÀYÀN ÀLỌ́ ÌJÀPÁ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kíka ìtàn Ìjàpá, Àgbò àti Igbá
5.0 Ìsọniṣókí
6.0 Ìbéèrè
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÀRÀ

Ní abẹ́ módù yìí, a ṣe àtúpalẹ̀ àwọn àṣàyàn àlọ́ ìjàpá mẹ́rin. A ṣe àkójọpọ̀ àwọn àlọ́ wọ̀nyí fún akẹ́kọ̀ọ́ láti kà fún ìgbà àkọ́kọ́ láti le ṣe àmúlò àwọn ohun tí a ti ń ṣe àgbéyẹ̀wò wọn lábẹ́ módù kínní dé ìkẹta fún àtúpalẹ̀ àwọn àlọ́ wọ̀nyí. Iṣẹ́ àdáṣe ni èyí jẹ́ fún akẹ́kọ̀ọ́.

Ìpín kínní: Ìtàn Ìjàpá, Àgbò àti Igbá
Ìpín kejì: Ìjàpá lóyún Ìjàngbọn
Ìpín kẹta: Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn
Ìpín kẹrin: Ìjàpá, Ajá, Ẹkùn àti Ọdẹ

Títí di ìsinyìí, ìwọ kò tí ì ní àǹfààní àti ka ìtàn kan ní kíkún. Nítorí ohun tí a ti ń yẹ̀wò láti módù kínní dé ìkẹta ni àwọn èròjà inú àlọ́ àti àwọn ọ̀ṣùwọ̀n tí a le lò láti ṣe àtúpalẹ̀ àlọ́. Àwọn èròjà yìí níìwọ yóò lò láti ṣe àtúpalẹ̀ ìtàn yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ yóò le:

(i) ka ìtàn náà fúnra rẹ kí ó sì mọ̀ ọ́n
(ii) dáhùn àwọn ìbéèrè tó rọ̀mọ́ ìtàn náà fúnra rẹ
(iii) mọ bí a ṣe ń ṣe ìtúpalẹ̀ àlọ́ nípa lílo àwọn èròjà ìtúpalẹ̀ tí a ti gbéyẹ̀wò ní módù kínní sí ìkẹta (modules 1 – 3).

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Irú ẹranko wo ni à ń pè ní àgbà?
2. Ohun méjì wo ni à ń lo igbá fún?

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Ka ìtàn inú ìpín yìí – Ìtàn Ìjàpá, Àgbò àti Igbá

Apàlọ́: Àlọ́ o!
Àwọn Jànmọ: Àlọ́!
Apàlọ́: Àlọ́ mi dá fììrìgbágbòó, ó dálérí
Ìjàpá, Tìrókò, ọkọ Yánníbo
Ẹsẹ̀ dan-ìn-dan-ìn bí àrán ọ̀pẹ
Tí ń lọ láàrin ẹ̀pà,
Ó ní ọpẹ́lọpẹ́ pé òun ga!

Ní ìgbà kan, ní ìlú Ìjàpá, àgbẹ̀ tó bá gbin igbá, ó ti bọ́ sí àmù owó ni; igbá tà púpọ̀, ó sì níyelórí. Gẹ́gẹ́ bí àwọn àgbẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá ti kú lé kòkó lónìí, ni àwọn àgbẹ̀ ìlú Ìjàpá náà ka ìgbá sí ohun ọrọ̀ pàtàkì. Torí náà, àgbẹ̀ tí kò bá gbin igbá kò lè fọwọ́ sọ̀yà pé àgbẹ̀ gidi lòun.

Ìjàpá wo ara rẹ̀ títí ní ọjọ́ kan, ó ní 'Gbogbo àgbẹ̀, igbá ni wọ́n fi ń ṣe ohun ọrọ̀. Ọmọdé gbin igbá, àgbà gbìn, wọ́n ń rówó ṣe. Èmi náà á lọ gbin igbá.Mo tilẹ̀ ti kíyèsí bí wọ́n ti ń ṣe é. Ṣé kénìyàn kàn gbin igbá ni, kò mú wàhálà dání; kò sí pé à ń ro oko fún un, fúnra rẹ̀ ni yóò tàn bo oko tí yóò pa á. Èmi náà fẹ́ di àgbẹ̀ tó lórúkọ – àgbẹ̀ onígbá.' Alábahun bá he àdá àti ọkọ́ rẹ̀, ó lọ síbi oko kan báyìí lọ́nà jíjìn sí abúlé rẹ̀, ó pa oko, ó tó yàrá kan ní títóbi, ó gbin ìdí igbá kan síbẹ̀, ó ní èyiùn náà tó bá tàn kálẹ̀, ó tó. Ṣé kí àwọn ará abúlé sá mọ̀ pé òun ní igbá lóko ni.

Bó ti gbin igbá yìí tán, ó gbéra, ó bọ̀ wálé.Kò padà débẹ̀ títí ọdún fi yípo. Ó ń sùn, ó ń jí; ó ń fi àwọn tí ńlọ sóko dá àpárá pé olóòrayè ni wọ́n, títàn ni igbá ń tàn kálẹ̀, èmi loko-ríro wá ti jẹ́, fúnra rẹ̀ kí yóò poko ni! Ó ń wò ní tirẹ̀, ó ń sùn, ó ń jí.

Nígbà tí ọdún jọ, onígbá ń ka'gbá, wọ́n ń tà á, wọn ń fowó rẹ̀ dá aṣọ sára, wọ́n ń jẹun, wọ́n ń gbádùn. Ìjàpá dìde níjọ́ kan, ó múra ó di oko. Ó fa agbọ̀n lọ́wọ́ ó ń lọ kérè igbá tirẹ̀.Bó ti débẹ̀ ló ní, 'Háà, igbá burúkú yìí! Eyọ kan ṣoṣo ló so. Àwọn ẹgbẹ́ rẹ ń so ogún, wọ́n ń so ọgbọ̀n, ẹyọ kan ṣoṣo ni ìwọ lè so. Ó mà kúkú yọ̀lẹ o! kò burú; ọ̀kan náà tilẹ̀ tóbi dáadáa. N ò gbé e bẹ́ẹ̀, a mú owó díẹ̀ wá tí mo bá tà á.'

Ǹ jẹ́ kó bẹ̀rẹ̀ kó gbé igbá, ni igbá bá sọ̀rọ̀ ló wí pé, 'Ìjàpá, o ṣé o. mo mọ̀ pé ọ̀lẹ ni mí, ṣùgbọ́n jẹ́jẹ́ mi ni mo jókòó tó wá gbìn mí sínú igbó yìí o. Lọ wo àwọn àgbẹ̀ ẹgbẹ́ rẹ, ìgbà gbogbo ni wọ́n ń roko fún igbá wọn kí oúnjẹ bá lè tó wọn, atẹ́gùn àlàáfíà a sì fẹ́ sí wọn. Oúnjẹ rere àti atẹ́gùn tó tutù ló ń mú igbá so dáadáa. Èmi nìyí, àtèṣín tó ti fi mí síbí, ẹ̀ẹ̀melòó ló wá bẹ̀ mí wò? Ǹjẹ́ o tilẹ̀ bìkítà àti roko fún mi?o kò náání bóyá mo jẹun

bóyá n kò jẹun. Lónìí, o wá fẹ́ kórè ohun tí o kò ṣe wàhálà fún. Jọ̀wọ́ máa bá tirẹ̀ lọ o, fi mi sílẹ̀ jẹ́jẹ́ o, tí o kò bá fẹ́ kàn din nínú iyọ̀ o.'

Ẹ̀rù ba Ìjàpá nígbà tó gbọ́ ọ̀rọ̀ tí igbá yìí sọ, ó sì yà á lẹ́nu pé igbá lè sọ̀rọ̀. Ṣùgbọ́n síbẹ̀síbẹ̀ ó pinnu pé níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé òun lòun gbin igbá yìí, dandan ni kóun gbé e lọ tà. Bó ti bẹ̀rẹ̀ pé kóun gbé igbá àfi gbàà, ni igbá fò tó kan Ìjàpá níkòó lórí; Ìjàpá fìdí jálẹ̀, ó ṣubú. Bó ti wo iwájú ló tún rí igbá ló ń yí gbirigidi bọ̀ lọ́dọ̀ rẹ̀. Ìjàpá fi eré sí i, igbásáré tẹ̀lé e, ó di gbirigidi gbirigidi gbirigidi, ó di kìtà kìtà kìtà, ni Ìjàpá ń ké pe àwọn ẹranko tó pàdé lọ́nà pé kí wọn gba òun lọ́wọ́ igbá tó ń lé òun, ló ń kọrin báyìí pé:

*Igbá ńl'Áhun,*
*Teregúngún màjàgúngún tere*
*Igbá ò lọ́wọ́*
*Teregúngún màjàgúngún tere*
*Igbá ò lẹ́sẹ̀*
*Teregúngún màjàgúngún tere*
*Igbá ńl'Áhun,*
*Teregúngún màjàgúngún tere*
*Igbá ò lọ́wọ́*
*Teregúngún màjàgúngún tere*
*Igbá ò lẹ́sẹ̀*
*Teregúngún màjàgúngún tere*

Gbogbo àwọn ẹranko tó pàdé lọ́nà ni wọ́n ń fi í ṣe ẹlẹ́yà tí wọ́n ní kí igbá mú un dáadáa. Nígbà tó yá, tó kù díẹ̀ kí igbá bá a, ni Ìjàpá bá pàdé Àgbò lọ́nà. Ó bẹ Àgbò kó ran òun lọ́wọ́, kó bá òun kan igbá pa. àgbò ṣàánú fún un, ó bẹ̀rẹ̀ sí í kan igbá, ó kàn án títí tí igbá fi fọ́ wẹ́wẹ́.

Ìjàpá bá bẹ̀rẹ̀, ó ṣa èfífọ́ igbá, ó ní òun á lọ tà á bẹ́ẹ̀. Ó mú èfífọ́ igbá kékeré kan fún Àgbò. Àgbò ni òun ò fẹ́ igbá, iṣẹ́ gidi lòun ṣe fún Ìjàpá, láìjẹ́ pé òun bá a kan igbá pa, pípa ni igbá yẹn ìbá pa Ahun. Torí náà, iṣẹ́ lòun fẹ́ kó lọ bá òun ṣe lóko òun.Ìjàpá gbà bẹ́ẹ̀, ó tẹ̀lé Àgbò lọ sí oko rẹ̀.

Àgbò mẹ́sẹ̀ oko kan, Ìjàpá náà mú tirẹ̀. Ṣùgbọ́n nítorí pé ọ̀lẹ ni, wéré ni Àgbò kọjá lára rẹ̀, tó ń roko lọ níwájú. Ìjàpá ń rò nínú ara rẹ̀ pé, tòun bá lè pa Àgbò yìí, àtoko rẹ̀, àti igbá yìí, yóò di tòun, òun yóò sì tún fi ẹran rẹ̀ se ẹ̀bẹ jẹ. Ó dára, ó ń roko lọ, ó ń wá ọ̀nà àtipa Àgbò.

Nígbà tí Àgbò ro oko tán, ààrẹ̀ ti mú u, ó bá lọ síbi odò tó wà lẹ́bàá oko rẹ̀, ó mu omi, ó fi ẹ̀yìn ti igi kan, láìpẹ́ ó sùn lọ. Nígbà tí Ìjàpá retí rẹ̀ tí kò tètè rí i, ló bá dìde, ó ń lọ sí ibi odò náà.Nígbà tó débẹ̀, ó rí i pé Àgbò ti ń hanrun. Ló bá wò yíká, ó rí igi ẹlẹ́nu ṣóńṣó kan ló bá mú u, ó rọra yọ́ lọ síbi tí Àgbò sùn sí, àfi ṣọ̀-ọ̀! Ó tẹ igi bọ Àgbò lójú, ó fi ẹ̀rú-ọkọ́ gbá a wọlẹ̀ dáadáa.Àgbò jà jà jà; ibẹ̀ ló kú sí.

Ìjàpá gbé òkú Àgbò lọ sí abà rẹ̀, ó kun ún, ó sè é, ó ń tasánsán. Bó ti sọ̀ ọ́ kalẹ̀ lórí iná, ọbẹ̀ náà sì gbóná jù; ló bá forí lé àgbẹ̀dẹ̀ Ajá tó wà nítòsí abà rẹ̀. Bó ti débẹ̀ ló rí Ajá tí ń rọ àdá, tó ń fi apákan ń fínná tó ń fi apákan lu irin-ọmọ-iṣẹ́ Ajá kò sí nílé. Ni Ìjàpá bá sọ fún Ajá pé òun fẹ́ bá a fínná.Ajá gbà, ó sì gbé ẹwìrì lé Ìjàpá lọ́wọ́. Gbígbà tí Ìjàpá gba ẹwìrì, ọkàn rẹ̀ kò kúrò níbi ìkòkò àgbò rẹ̀, orin ló fẹwìrì ń kọ, ló ń pé:

*Ìkòkò àgbò ḿbẹ lájà*
*Ìkòkò àgbò ḿbẹ lájà*
*Tó kún bámúbámú*
*Tó kún bámúbámú*
*Ìkòkò àgbò tó dùn ḿbẹ lájà*
*Tí mo bá délé má mú jẹ*
*Tí mo bá délé má mú jẹ*
*Ìkòkò àgbò*
*Ìkòkò àgbò ḿbẹ lájà*

Inú rẹ̀ ń dùn, itọ́ ń súyọ lẹ́nu rẹ̀, ó dàbí ẹni pé ó ń gbóòórùn títasánsán ẹ̀bẹ tó fàgbò sè; ó ń fínná mẹ́sàn-án mẹ́wàá, ó n fẹwìrì kọrin.

Àṣe gbogbo bó ti ń ṣe ni Ajá ń kíyèsí. Alágbẹ̀dẹ kúkú ni, gbogbo ohun tí ènìyàn lè fi ẹwìrì sọ ló ti yé e. nígbà tí ó gbọ́ orin tí Ìjàpá ń fẹwìrì kọ, ó yára mú irin tó fi ń rọ àdá, ó mú u padà sínú iná, ó kó èédú síná, ó ní kí Ìjàpá máa fínná, òun ḿbọ̀, òun fẹ́ yára ṣègbọ̀nsẹ̀ lóko kan lẹ́bàá àgbẹ̀dẹ náà. Kọ́rọ́ t'Ájá yí wọnú ìgbẹ́, ahéré Ìjàpá ló sáré lọ.Bó ti débẹ̀, kòì tí ì wọlé tó ti ń gbọ́ òórùn títasánsán ọbẹ̀ Ìjàpá.Ní ìṣẹ́jú-akàn, Ajá ti gun òkè àjà, ó gbé ìkòkò àgbò sọ̀kalẹ̀, ó fi gbogbo rẹ̀ jẹ pátápátá; kìkì eegun díẹ̀díẹ̀ ló fi sílẹ̀ níbẹ̀.Kálàǹgbá tó paradà lẹ́gbẹ̀ẹ́ ògiri, Ajá ti padà sí àgbẹ̀dẹ.Ó kí Ìjàpá kú iṣẹ́, ooru ḿbo Ìjàpá wọ̀ọ̀; ajá ní, 'Kú iṣẹ́ ọ̀rẹ́ mi. Ǹjẹ́ kò ti rẹ̀ ọ́ díẹ̀ bẹ̀ẹ̀?Jẹ́ kí n ràn ọ́ lọ́wọ́, kó o sinmi, kó o gbatẹ́gùn sára díẹ̀.'

Ajá gba ẹwìrì, ló ń pé:

*Ìkòkò àgbò ḿbẹ lájà*
*Ìkòkò àgbò ḿbẹ lájà*
*Mo ti jẹ é tán.*
*Mo ti fi í lánu*
*Pátápátá po, pátá po, pátápátá po.*

Ìjàpá fura pé ǹjẹ́ ìkòkò àgbò n kọ́ l'Ajá sọ pé òun jẹ tán yìí?Ó yára kí ọ̀rẹ́ rẹ̀ pé ó dìgbóóṣe, òun fẹ́ yára lọ bẹ́lé wò.

Nígbà tí Ìjàpá délé, ìkòkò àgbò rẹ̀ ló bá nílẹ̀; egungun àgbò nìkan ló kù, gbogbo ẹ̀gbẹ́ ìkòkò ni Ajá ti fahọ́n lá, tí ń dán kooro. Ìjàpá gbójú sókè,

omi ló bọ́ lójú rẹ̀.Kí ló lè ṣe?Kò lè pe Ajá lẹ́jọ́ sílé-ẹjọ́ àwọn ẹranko nítorí kò ní lè fìdí ẹjọ́ rẹ̀ múlẹ̀; kò kúkú mú Ajá níbi tó ń gbé ń jí ìkòkò àgbò jẹ.Nibo lòun ó ti ní òun rí àgbò sè. Ẹjọ́ apànìyàn ni wọn yóò tún ṣe fún òun, nítorí òfin wà pé ẹranko kan kò gbọdọ̀ pa ẹranko ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ jẹ àfi Kìnnìún, Ẹkùn àti Ìkookò ni wọ́n fún láṣẹ. Tóun bá pẹjọ́, òun yóò tún jẹ ìyà kún ìyà ni, nítorí bí ọwọ́ èniyàn kò bá tí ì tẹ èèkù idà, kì í bèèrè ikú tó pa ìyá òun. Sùúrù lòun ó mú.

Báyìí ni Ìjàpá pa Àgbò tó gbà á sílẹ̀ lọ́wọ́ Igbá tí ìbá pa á.Ṣùgbọ́n, Ọlọ́run rán Ajá láti gbẹ̀san ibi tó ṣe sí Àgbò. Ìtàn yìí kọ́ wa pé a kò gbọdọ̀ fi ibi san oore o. Dípò bẹ́ẹ̀, ire ló yẹ ká fi san ibi o.

*Ìdí àlọ́ mi rèé gbáńgbáláká;*
*Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà;*
*Bí n bá purọ́, kágogo ẹnu mi má ròó,*
*Bí n ò bá purọ, kágogo ẹnu mi ró lẹ́ẹ̀mẹta –*
*Ó di …pó….pó….pó!*

Orísun ìtàn: Babalọla (1973)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìtàn yìí, a rí i bí Ìjàpá ti fi ibi san oore fún Àgbò tí ó gbà á sílẹ̀ lọ́wọ́ Igbá. Igbá fẹ́ pa Ìjàpá lẹ́yìn ìgbà tí ó fi ṣe ẹlẹ́yà ṣùgbọ́n Àgbò ràn án lọ́wọ́ láti kan Igbá pa. Ìjàpá pa Àgbò; ó fi ibi san ire. Lẹ́yìn ìgbà tí ó pa Àgbò tí ó sì fi ẹran rẹ̀ se ẹ̀bẹ aládùn, Ajá ni ó kérè gbogbo oúnjẹ tí Ìjàpá sè.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

**Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó rọ̀mọ́ ìtàn yìí:**

1. Kí ni ìdí tí Ìjàpá fi dá oko igbá?
2. Kí ni ìdí tí Igbá fi bá Ìjàpá jà?

3a. Ta ni ó gba Ìjàpá sílẹ̀ lọ́wọ́ Igbá?
b. Ọ̀nà wo ni ó fi gba Ìjàpá sílẹ̀?

4. Dárúkọ àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú ìtàn yìí
5. Irú ẹ̀dá-ìtàn wo ni a lè pe Ìjàpá? Fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Babalọlá, A. (1973) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá,* Apá Kínní. Ibadan: University Press Ltd.

# ÌPÍN KEJÌ: ÌTÀN ÌJÀPÁ LÓYÚN ÌJÀǸGBỌ̀N

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Kíka ìtàn Ìjàpá Lóyún Ìjàǹgbọn
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Wo ìfáárà abẹ́ ìpín kínní

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Èyí kò yàtọ̀ sí ti abẹ́ ìpín kínní

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kí ni orúkọ ìyàwó ìjàpá nínú àlọ́?
2. Irú ẹ̀dá-ìtàn wo ni ìjàpá?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ka ìtàn inú ìpín yìí – Ìtàn Ìjàpá Lóyún Ìjàngbọ̀n

Apàlọ́: Àlọ́ o!
Àwọn Jànmọ: Àlọ́!
Apàlọ́: Àlọ́ mi dá gbà-á, ó dá gbò-ó, ó dá fìrìgbágbòó, ó dálérí Alábahun Ìjàpá

Nígbà tí Ìjàpá di ọmọ ọdún mẹ́ẹ̀ẹ́dógún, ó fẹ́ ìyàwó kan; Yánníbo lorúkọ ìyàwó rẹ̀. Yánníbo jẹ́ arẹwà obìnrin; ó pupa ròbòtò, eyín ẹnu rẹ̀ funfun nigín-nigín. Bí àṣẹ̀ṣẹ̀yọ ọ̀gọ́mọ̀, ó gùn, ó síngbọnlẹ̀, ó rí sọ́sọ́rọ́ díẹ̀. Bó wọ aṣọ, á yẹ ẹ́, bó bọ bàtà, à bá a mu, bó ń rìn lọ, ó mú irin wu ni. Bí ọmọbìnrin yìí ti lẹ́wà tó, bẹ́ẹ̀ ló níwà: ó lè gé ara rẹ̀ fi tọrẹ, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àánú ní ḿbẹ níhò ojú rẹ̀, ó lọ́yàyà, ó sì nífẹ̀ẹ́ sí tọmọdétàgbà. Ṣùgbọ́n inú rẹ̀ kò dùn tó bẹ́ẹ̀ nítorí pé kò bímọ. Bí kò sí ti bímọ yìí náà, kò bínú ẹrú kò bínú ọmọ; bí ẹnìkan bá bímọ ní ilé wọn tàbí ní àdúgbò, Yánníbo ló ḿbá wọn tọ́jú rẹ̀; á wẹ̀ fún ọmọ ọlọ́mọ, a kun àtíkè fún un, á pọn ọ́n; bó ṣu òun ni yóò kó o, bó tọ̀ òun ni yóò nù ú, ó sá ń tọ́jú gbogbo ọmọ wẹ̀ẹrẹ tó

bá rí, á máa yan sàká, á máa se oúnjẹ fún wọn, bóyá nípa bẹ́ẹ̀ òun náà á dọlọ́mọ. Òtúbáńtẹ́.

Nígbà tó di ogún ọdún tí Yánníbo ti délé ọkọ tí kò lóyún ọjọ kan súlẹ̀, ó pe ọkọ rẹ̀, ó ní 'Baálé mi, ọkọ àyà mi, olówó orí mi, ọ̀rọ̀ ẹ̀dùn ọkàn mi gan-an ni mo fẹ́ bá yín sọ. Láti ogún ọdún tí a ti ḿbá á bọ̀ yìí, ẹ kò ṣẹ̀ mí, ẹ kò hùwà kan tí kò tẹ́ mi lọ́rùn sí mi. Èmi náà sì ń ṣagbára mi láti máa mú inú yín dùn. Ṣùgbọ́n nǹkan tí ń kọ mi lóminú, tó sì ń bà mí nínú jẹ́ ni àìrọ́mọbí. Ère kí ni obìnrin lè jẹ nílé ọkọ láìbímọ? Ẹwà obìnrin ni ọmọ jẹ́, òun sì ló ń koná ìfẹ́ láàrin ọkọ àti aya. Nítorí náà, ẹ bá mi wá aájò ṣe; kìí ṣe pé ẹ ti káwọ́bọtan láti ọjọ́ yìí wá, rárá, n kò sọ ìyẹn; ṣùgbọ́n àwọn àgbà ló ń pa á lówe pé, "Bí iná kò bá tán lórí, ẹ̀jẹ̀ kì í tán ní èékánná' kí òwe náà jẹ́ tiyín; bí a kòì rí ọmọ bí a kò gbọdọ̀ jẹ́ kí agara dá wa o.

'Mo dúpẹ púpọ̀ lọ́wọ́ rẹ, ìyàwó mi ọ̀kẹ́mú; o ò ní pasán nílé mi. Ọ̀gẹ̀dẹ̀ kì í yàgàn, Olódùmarè kò ní í ṣe ọ́ lágàn, ọmọ alálùbáríkà ni Ọlọ́run yóò fi dá wa lọ́lá. Èmi náà kò jẹ́ rẹ̀wẹ̀sì, lọ́sàn-án lórú ni mò ń ro ọ̀nà tí a ó gbà tí a ó fi dọlọ́mọ. Ṣé ìwọ náà rí i pé n kò fẹ́ obìnrin mìíràn, n kò sì bímọ sí ìpamọ́. Bí ó ti rí lára rẹ, bẹ́ẹ̀ lókàn mí gbọ̀ngbọ̀n. Mo mọ̀ pé a ó bímọ, ọmọ tí yóò gbẹ̀yìn tẹ́yìnṣe ni Ọlọ́run yóò sì pèsè fún wa, apẹ́-kó-tó-jẹun kò ní í jẹ ìbàjẹ́. Tújúká, ìyàwó mi, Ọlọ́run ni ń ṣọmọ. N ó lọ bá ọ̀rẹ́ mi kan tó jẹ́ babaláwo tó gbójú, alẹ́ yìí gan-an ni n ó lọ ibẹ̀.'

Àkàlà ni babaláwo náà tí Ìjàpá fẹ́ lọ bá; ọ̀rẹ́ ni òun àti Ìjàpá ṣùgbọ́n, láti ìgbà tí Ìjàpá ti ń wá ọmọ, kò fi lọ ọ̀rẹ́ rẹ̀ yìí, àwọn babaláwo ìlú òkèèrè ló lọ ń bá tó ń náwó tó ń nára. Bẹ́ẹ̀ ni ògbólògbó adáhunṣe àti olóògùn ni Àkàlà ń ṣe, ẹbọ ló rú títí tí orí rẹ̀ fi pá. Ohun tí a ní kì í jọ ni lójú, ni kò jẹ́ kí Ìjàpá ti fi ẹ̀dùn ọkàn rẹ̀ lọ Àkàlà. Nísinsìnyìí, ó dìde, ó lọ sọ́dọ̀ Àkàlà, ó sọ fún un wí pé, 'Ọ̀rẹ́ mi Àkàlà, inú mi dùn bí mo ti bá ọ yìí, tó o jókòó láàrin àwọn ọmọ àti ìyàwó rẹ, tó ń jẹ tó ń mu; tó rọ́mọ pè rán nísẹ́, to rọ́mọ bá sọ̀rọ̀, tí àwọn aládùúgbò ń fi orúkọ ọmọ pè ọ́. Ìbá jẹ́ rí bẹ́ẹ̀ fémi náà, ayọ̀ mi ìbá túbọ̀ kún. A sá jọ gbéyàwó ní sáà kan náà ni. Ọlọ́run kò sì fún wa lọ́mọ, jọ̀wọ́ mo bẹ̀ ọ́, a kì í mọ ènìyàn mẹ́fà kójú ẹgbàafà pọ́n ni, babaláwo ni ọ́, bá mi késí Ọ̀sanyìn rẹ kó ṣòògùn oyún fún ìyàwó mi.'

'O ṣeun, ọ̀rẹ́ mi Ìjàpá. N kò ṣàì ń ro ọ̀rọ̀ tìrẹ yìí. Níjọ́ wo ná ni èmi àti ìyàwó mi ń sọ̀rọ̀ rẹ níbi yìí, tí à ń gbàdúrà kỌ́lọ́run ṣí ìyàwó rẹ nínú. Èrò-ọkàn tèmi ni pé ìgbà tí ẹ kò sọ fún wa, mo ti gbà pé ẹ ti rí àwọn tó ń ṣaájò fún yín ni. Ìpè tí a sì gbọ́ là á jẹ́. Nísisìyìí tí ó wá sọ fún mi yìí, n ó sa ipá mi, ìyàwó rẹ yóò sì lóyún. Ṣùgbọ́n kin ní kan ni o, nítorí ọ̀rọ̀ rẹ ṣòro, òògùn tèmi ní èèwọ̀ o: o ò gbọdọ̀ tọ́ ọ wò, tí o bá tọ́ ọ wò, o ó lóyún o, kí lo máa ṣe bí ọmọ náà? Kò sí, àfi ikú o. Torí náà, mo kìlọ̀ fún ọ gidigidi o, kò sí ẹ̀rọ̀ rẹ̀ o.'

'Háà!kí ló máa sún mi sí yẹn? Ohun tí mo ti ń wàhálà fún láti ogún ọdún sẹ́yìn kí n tún wá fọwọ́ ara mi ṣe ara mi! Ńdào, n kìí ṣọmọdé, àgbà ni mo dà yìí, torí náà ohun tó bá ní ṣiṣe ni kó o sọ fún mi; pé n máa fọwọ́ kàn án yẹn, ká mú u kúrò, n kò jẹ́ jẹ oṣẹ.'

'Inú midùn láti gbọ́ ìlérí tí o ṣe. Ohun ìrúbọ tó máa wá, ta ó fi ṣètùtù ni màláù méje, ewúrẹ́ méje, àgbò méje, òbúkọ méje, ẹyẹlé méje, adìẹ mẹ́rìnlá: àkùkọ méje, àgbébọ̀ méje. Ìgò epo méje, egbìnrín iyọ̀ méje, ata méje, àpò àlùbọ́sà méje. Lẹ́yìn ìyẹn, o ó wà á lọ ra odindi ẹja àrọ̀ tí wọ́n ká, tí wọ́n ti yangbẹ, tó jẹ́ ọ̀wọ̀jú, èyí la ó fi se àṣèjẹ fún aya rẹ lẹ́yìn tí a bá ti rúbọ tí a sì ti tu Èṣù lójú. Tí o bá lè ṣe gbogbo ohun tí mo kà sílẹ̀ yìí, ìyàwó rẹ kò ní mú oṣù náà jẹ, oyún ni yóò fi ní o.'

Ìjàpá dúpẹ́ lọ́wọ́ Àkàlà, ó gbéra, ó relé rẹ̀.ó kó, ó rò fún ìyàwó rẹ̀; nígbà tó sì dọjọ́ kejì, wọ́n wá gbogbo ohun tí Àkàlà kà sílẹ̀, ó pé pérépéré. Ìjàpá kó o lọ fún Àkàlà, babaláwo náà sì sọ fún un pé tó bá di òwúrọ̀ ọjọ́ kejì, kó wá gba àsèjẹ ìyàwó rẹ̀ o.

Àkàlà rúbọ, ó tú èrù atùkèṣù, ó se àsèjẹ fún Yánníbo, ọbẹ̀ náà ń ta sánsán, ẹja àrọ̀ yẹn tóbi, ó fọ́ kẹ́rẹ́kẹ́rẹ sínú ọbẹ̀ náà, ó ń pọ́n tọ̀ọ̀, epo ń ṣàn geere lójú ọbẹ̀ náà, irú, ògìrì àti àlùbọ́sà kò jẹ́ kénìyàn lè mójúkúrò lára àsèjẹ náà, ó wọ ni lójú gidigidi.

Ìjàpá dé, gẹ́gẹ́ bí Àkàlà ti sọ fún un. Babaláwo gbé ọbẹ̀ lé e lọ́wọ́, ó sì tún kì í nílọ̀ pé kò gbọdọ̀ tọ́ ọ wò o, Yánníbo ló ni í o. Ó gba aàsèjẹ, ó dúpẹ́ lọ́wọ́ Àkàlà, ó lọ.

Bí ó ti ńlọ lọ́nà, ọbẹ̀ yìí ń ta sánsán sí i nímú, ó ń fi imú fa òórùn rẹ̀, ó ń dá ọ̀fun mì, itọ́ ń yọ́ sí i lẹ́nu, ó ń rò ó nínú ara rẹ̀ pé Yánníbo nìkan ni yóò jẹ ọbẹ̀ tí ń ta sánsán yìí. ṣebí obìnrin kò lè dánìkan bímọ, tóun bá tọ́ díẹ̀ wò níbẹ̀, nǹkan náà á fi tètè bọ́sí i ni. Ó dúró, ó ṣí ọbẹ̀ náà wò, ó rí ẹja àrọ̀ yẹn tó ti tú púyẹpúyẹ sínú ọbẹ̀, ó wọ̀ ọ́ lójú; ó gbé ọbẹ̀ sílẹ̀, ó na ọwọ́ kóun mú iṣu ẹja kan jẹ, ó tún sáwọ́ kì, ọkàn rẹ̀ kàn sọ fún un pé wọ́n mà ti kìlọ̀ fún òun tẹ́lẹ̀ kóun má tọ̀ ọ́ wò; ó dé e padà, ó gbé e, ó ńlọ́. Bó ti tún rìn díẹ̀, ó tún dúró, ó ṣí ọbẹ̀; tóun bá mú iṣu ẹja kan lásán, ìyẹn ò ba òògùn jẹ́ kẹ̀, òun ò sì tí ì lè fi ìyẹn lóyún; báwo lọkùnrin tilẹ̀ máa ṣe lóyún, òun ò gbọ́ ọ rí. Ìjàpá mú irú ẹja pùkẹ̀pùkẹ̀ kan, ó sọ ọ́ sẹ́nu ṣọ́dú, ó gbé ìṣaàsùn rẹ̀ ó ń lọ, ó ń jẹ ẹja yẹn ní àjẹrìn. Nígbà tí ó jẹ ẹ́ tán, ó dùn mọ́ ọn lẹ́nu, ó ní àṣé ohun tó dùn báyìí ni Àkàlà ní kí Yánníbo nìkan jẹ, bóyá ó tilẹ̀ fẹ́ gba ìyàwó òun náà ló ṣe ṣebẹ̀ tó dùn báyìí lọ fún un. Òun á jẹ eléyìí, ẹni tó ní kóun má jẹ ẹ́, kólúwa rẹ̀ kú, kó rùn, kó dojúbolẹ̀ gbìrìgidi bí ìgbín. Òun lòun ni owó tóun fi ra nǹkan tí wọ́n fi sè é, ọ̀rẹ́ òun ló sì sè é, tòun bá jẹ èyí, òun á tún lọ bá a kó se òmíràn pé ewé kòì jẹ́.

Ìjàpá gbé ọbẹ̀ kalẹ̀ nídìí igi kan, ó fọwọ́ sí i, ó jẹ gbogbo rẹ̀ pátápátá, ó fọ́ ìsáàsùn mọ́lẹ̀ níbẹ̀. Ó dìde, ó ń lọlé pé òun á lọ sọ fún Yánníbo pé Àkàlà kòì se àsèjẹ rẹ̀ o. Bó ti ń lọ lọ́nà, ni inú bẹ̀rẹ̀ sí í mú u, inú rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí í ga, ó ń fẹ̀, ó ń tóbi, ó ń ga á lẹ́mìí, kò lè mí dáadáa mọ́, ó ń kérora. Nígbà tí inú yìí fẹ́ bẹ́, ló bá ṣẹ́rí padà, ó ní òun á lọ bẹ Àkàlà kó bá òun rọ kinní yìí, kó ṣe ètùtù fún òun, òun á purọ́ pé gbòǹgbò ló yọ òun ṣubú tí ọbẹ̀ dànù, tí díẹ̀ sì kán sí òun lẹ́nu; ló bá padà, ló ń sáré lọ sílé Àkàlà, ikùn ti di gbandu, kò jẹ́ kó lè sáré mọ́, ó túbọ̀ ń tóbi sí i ní ìṣìṣẹ́jú ni. Nigbà tó rílé Àkàlà lọ̀ọ̀ọ̀kán ló forin sẹ́nu, tó ń kọ ọ́ tàánú tàánú pé:

*Bàbaláwo, mò wá bẹ̀bẹ̀,*
*Alugbinrin.*
*Bàbaláwo, mò wá bẹ̀bẹ̀,*
*Alugbinrin.*
*Òògùn tó ṣe fún mi lẹ́rẹ̀kàn.*
*Alugbinrin.*
*Tó ní n má mà mọ́wọ́ kan'nu,*
*Alugbinrin.*
*Tó ní n má mà mẹ́sẹ̀ kan 'nu,*
*Alugbinrin.*
*Gbòǹgbò ló yọ̀ mí tẹ̀rẹ̀,*
*Alugbinrin.*
*Mo fọwọ́ bà 'bẹ̀, mo mú ba'nu,*
*Alugbinrin.*
*Mo bo'jú wo'kùn, ó yó kẹ́ndu,*
*Alugbinrin.*
*Bàbaláwo, mò wá bẹ̀bẹ̀,*
*Alugbinrin.*
*Bàbaláwo, mò wá bẹ̀bẹ̀,*
*Alugbinrin.*

Nígbà tí Àkàlà rí i, ó yanu kò le pa á dé, ó ní, 'Ìjàpá, o ṣè yìí tán!Mo sọ fún ọ tàbí n kò sọ fún ọ? Kò sí ẹ̀rọ̀ rẹ̀! Ikú ni. Èrè àìgbọràn àti ojúkòkòrò ló jẹ yìí o.'

Ìjàpá bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ̀bẹ̀, ó ń wí àwáwí, ó ń sunkún, ó ń kégbe, Àkàlà ní kí ó lọ sójú Ọ̀sanyìn, kí ó lọ bẹ̀ ẹ́ nítorí Ọ̀sanyìn ni òrìṣà ìṣègùn, bóyá ó lè rí ìwòsàn ṣùgbọ́n òun ò mọ ẹ̀rọ̀ rẹ̀. Bó jẹ́ obìnrin ló jẹ àsèjẹ yẹn, ọmọ ni yóò fi bí, ṣùgbọ́n òun ò rí ọkùnrin tó bímọ rí o.

Ìjàpá fi ìdí wọ́ dé ojú Ọ̀sanyìn, ó dọ̀bálẹ̀, ó ḿbẹ̀bẹ̀. Ọ̀sanyìn ni ó ti jẹ èèwọ̀, ẹ̀mí rẹ̀ ni yóò fi ṣe ètùtù. Ìgbàtí inú Ìjàpá tóbi títítí, ló bá bẹ́ pò ó! Bí Ìjàpá ti kú ikú oró nítorí ojúkòkòrò àti àwìigbọ́ àkọ́-ìgbà nìyí o. Ojú òrìṣà Ọ̀sanyìn ló kú sí o. Òun ni wọ́n ṣe ń fi Ìjàpá bọ Ọ̀sanyìn o. Ọ̀sanyìn bá gbé Ìjàpá, ó jẹ ẹ́ o.

*Ìdí àlọ́ mi rèé gbáńgbáláká;*
*Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà;*
*Bí n bá purọ́, kágogo ẹnu mi má ròó,*
*Bí n ò bá purọ, kágogo ẹnu mi ró lẹ́ẹ̀mẹta –*
*Ó di …pó….pó….pó!*Orísun ìtàn: Babalọla (1973)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìtàn yìí, a rí i bí ojúkókòrò ṣe pa Ìjàpá. Ìjàpá kú ikú oró sí ojú òrìṣà Ọ̀sanyìn lẹ́yìn ìgbà tí ó jẹ àsè èyí tí babaláwo ti kìlọ̀ fún un pé kò gbọdọ̀ jẹ níbẹ̀ nítorí Yánníbo ni a se àsè náà fún. Inú Ìjàpá wú tító tó fi bẹ́ tí ó sì kú.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Kí ni ìdí tí Ìjàpá fi tọ babaláwo lọ?
2. Kí ni àwọn ohun ti babaláwo ní kó mú wá fún ìrúbọ?
3. Àwọn èròjà wo ló wà nínú àlọ́ yìí. Wo módù kínní, ìpín kẹta fún ìtọ́nisọ́nà.
4. Ṣe àpèjúwe ìwà Ìjàpá
5. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ wo ni o rí fàyọ nínú ìtàn yìí? (Wo módù kejì, ìpín kínní fún ìtọ́sọ́nà)

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Babalọlá, A. (1973) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá,* Apá Kínní. Ibadan: University Press Ltd.

# ÌPÍN KẸTA: ÌJÀPÁ ÀTI BÀBÁ ONÍKÀN

**Àkóónú**


1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kíka Ìtàn Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Ìbéèrè
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Wo ìfáárà abẹ́ ìpín kínní

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Èyí kò yàtọ̀ sí ti ìpín kínní

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Orúkọ mìíràn wo ni Yorùbá ń pe ikàn?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ka ìtàn inú ìpín yìí – Ìtàn Ìjàpá àti Bàbá Oníkàn

Apàlọ́: Àlọ́ o!
Àwọn Jànmọ: Àlọ́!
Apàlọ́: Àlọ́ mi dá fìrìgbágbòó, ó dáléri Ìjàpá Ọkọ Yánníbo àti Bàbá Oníkàn kan.

Ní ìgbà kan, bàbá kan wà ní ìlú kan, ó gbin ikàn sí oko rẹ̀. Oko tí à ń wí yìí tóbi púpọ̀, jìnwìnnì ni ikàn rẹ̀ máa ń so; kò sẹ́ni tó máa rí oko ọkùnrin àgbẹ̀ yìí kí ikàn má wu olúwarẹ̀ jẹ. Bí Ìjàpá bá ń lọ sí ọjà ní ìlú kejì, ẹ̀bá oko ikàn yìí ló ń gbà kọjá; itọ́ á máa sú sí i lẹ́nu bí ó bá ti rí ìgbá tó so dọ̀ǹkùdọ̀ǹkù yìí, ọ̀fun a sì máa dá a; ṣùgbọ́n kò ní owó tí yóò fi rà á jẹ.

Nígbà tó dijọ́ kan, ebi ń pa á, kòì tí ì jẹun látàààrọ̀; ṣé àhejẹ ni Alábahun ń ṣe tẹ́lẹ̀, ilé àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ ló ti ń jẹun lẹ́ẹ̀mẹta lójúmọ́, ṣùgbọ́n ní ọjọ́ tí à ń wí yìí, púpọ̀ nínú àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ kò sí nílé, àwọn tó sì wà nílé kò ní oúnjẹ; ọjọ́ ọjà ni, gbogbo àwọn ìyàwó wọn ṣẹ̀ṣẹ̀ lọ ra nǹkan ọbẹ̀ ní ọjà ni.

Ebi wá ń pa Ìjàpá, kò fojú dá ibi tó ti lè jẹun; nígbà tí ódé oko bàbá oníkàn yìí, ó wọ ọ̀ lójú, ó wò yíká, kò rẹ́nìkankan, ó yà bàrá sí oko, ó

bẹ̀rẹ̀ sí í ká ikàn jẹ; ó jẹ ó yó, ó lọ sílé rẹ̀, ó délé, ó momi, ojú rẹ̀ wálẹ̀, ọkàn rẹ̀ balẹ̀, ayo dé. Láti ìgbàyí ni Ìjàpá ti lọ ń jí ìgbá bàbá yìí ká, kò tilẹ̀ délé ọ̀rẹ́ kankan mọ́, ó kúkú sọ ìgbá di tirẹ̀, ó ń mù, ó ń yọ̀ nínú oúnjẹ ọ̀fẹ́.

Bàbá oníkàn kíyèsí pé ọwọ́ òun ń yípadà nínú oko; igi ikàn tó bá so jìnwìnnì tí bàbá yìí bá fojú sọ pé òun yóò ká ní ọjọ́ kejì, kó tó dé lọ́jọ́ kejì náà, ilẹ̀ á ti gbẹ; Ìjàpá á ti fi í jẹ. Nígbà tó yá, bàbá yìí bá bẹ̀rẹ̀ sí í ṣépè fún ẹni tó wá ń jí òun ní ikàn ká:

"Ẹni tó wá jí ikàn yìí ká, ògún ni yóò pa olúwarẹ̀, ilẹ̀ ni yóò mú u; ọwọ́ rẹ̀ kò ní tẹ́nu, kò ní tẹ̀gbẹ́ kò ní bá ọ̀gbà mu…'

Ní ọjọ́ kan, Ìjàpá ṣì wà nínú oko nígbà tí bàbá oníkàn dé, tí ó bẹ̀rẹ̀ sí í ṣẹ́ èpè fún olè tí ń jí i níkàn. Ìjàpá ò lè rọ́nà jáde kólóko má rí i; ọgbọ́n wo lòun ó ta tóun yóò fi dẹ́rùba àgbẹ̀ yìí o? Èrò kan sọ sí i nínú, ló bá déédéé forin sẹ́nu, ó pé:

*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*
*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*
*Ìwọ ká, èmi ká,*
*Kínìnrínjingbin*
*Tèmi ṣe lè dèpè?*
*Kínìnrínjingbin*
*Èpè kan ò p'Ahun,*
*Kínìnrínjingbin*
*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*

Nígbà tí ọkùnrin yìí gbọ́ ohùn Ìjàpá lójijì bẹ̀ẹ̀, àyà rẹ̀ pami, ó ṣíyán kò dúró gbọbẹ̀, ó ń du bọ̀ nílé lẹ̀lẹ̀lẹ̀lẹ̀.Nígbà tó délé, ó kó, ó rò fún àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀; gbogbo wọn múra, wọ́n tún bá a padà sí oko.

Ìjàpá rèé, aláṣejù ni; nígbà tó rí i pé ọgbọ́n tóun ta ṣiṣẹ́, ó kúkú pẹbu sóko olóko bíi ọká, kò gbèrò àtitètè kúrò níbẹ̀. Nígbà tí oníkàn yìí àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ débẹ̀, wọ́n ní kí àgbẹ̀ náà ṣẹ́ èpè bó ti ṣe lákọ̀ọ́kọ́; bí ó ti bẹ̀rẹ̀ èpè ṣíṣẹ́, ni Ìjàpá tún forin sẹ́nu, tó yí ohùn padà gbá-a, tí gbohùn-gbohùn gba ohùn rẹ̀, tí gbogbo igbó gbojikan, ó ń pé:

*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*
*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*
*Ìwọ ká, èmi ká,*
*Kínìnrínjingbin*
*Tèmi ṣe lè dèpè?*
*Kínìnrínjingbin*
*Èpè kan ò p'Ahun,*
*Kínìnrínjingbin*
*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*

Àtàgbẹ̀ àtàwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀, ọ̀nà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n gbà délé. Òmíràn ṣubú nígbà tó ń sáré lọ, aṣọ òmíràn kọ́gi, ó fàya, òmíràn forí sẹgi, òmíràn fẹsẹ̀ dá.Wàràwéré, ọ̀rọ̀ yìí ti tàn dọ́dọ̀ ọba. Ọba ránṣẹ́ pe àgbẹ̀ yìí àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀, ó wá dìí òkodoro lẹ́nu wọn:

'Kábíyèsí, mo ní kọ́kàn mi túbọ̀ lélẹ̀ kí n máa bọ̀ lọ́dọ̀ yín ni mo rí oníṣẹ́ yín. Ó ti pẹ́ tí mo ti ń kíyèsí pé olè kan máa ń wá jí mi ní ikàn ká, mo ṣọ́ ọ títí n ò rí i mú. Ní òwúrọ̀ yìí bí mo ti jí dé oko, ni mo tún rí ọwọ́ tuntun lára ìgbá mi, mo bá mú èpè ṣẹ́. Àfi bí nǹkan náà ti déédéé dá mi lóhùn nínú oko; n kò mọ nǹkan náà, n kò sì gbọ́ irú ohùn bẹ́ẹ̀ rí.

'Mo sáré wálé, mo sọ fún àwọn ọ̀rẹ́ mi; gbogbo wá tún kó ra wa rẹirẹi, ó doko. Mo tún ṣẹ́pè bíi tàkọ́kọ́, ohun náà tún dá mi lóhùn; ó gba gbogbo igbó kan, àfi bíi ohùn àwọn ogun-ọ̀run, nítorí kò jọ ohùn aráyé kankan. Kábíyèsí, ẹnìkan nínú wa kò mọ̀ ọ̀nà tí ẹnìkejì gba padà sílé, ọ̀rán di bí-o-ò-lọ-yà-fún-mi, eré àsádijú lolúkúlùkù sá délé. Èyí tá a rí rè é o, kọ́ba ó pẹ́…'

Ọba ronú títí, ọ̀rọ̀ náà dòòyà, ó yà á lẹ́nu; òun nílàti tètè ròkan ṣe, nítorí èèmọ̀ ló ń bọ̀ nílùú yìí.'Ẹ bá mi késí àwọn babaláwo àti àwọn adáhunṣe tó wà nílùú, kí wọ́n wá lọ bẹ̀dí ọ̀ràn yìí wò.' Alágogo ọba kéde, ó lu agogo káàkiri ìlú. Ní òwúrọ̀ ọjọ́ kejì, àwọn awo ìlú péjọ; bàbá oníkàn mú wọn lọ síbi oko rẹ̀, ó ṣẹ́pè bó ti máa ń ṣe, alábahun tún kọrin bó ti ń kọ ọ́, ògbùrùgburu, àwọn awo sá bọ̀ sílé wọn; òmíràn fara gbọgbẹ́, àpò ifá ẹlòmíràn fàya, ẹlòmíràn ẹ̀wẹ̀ fi ẹsẹ̀ rọ́ nígbà tó ṣubú sínú kòtò, ó ń rìn yẹ́ńkúyẹ́nkú bíi amúkùn-ún kiri.

Nígbà tí ọba rí i pé ọwọ́ àwọn babaláwo kò ká ọ̀ràn tó wà nílẹ̀ yìí, ó késí Ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀kan. Ọ̀sanyìn ẹlẹ́sẹ̀kan rèé, òun ni Babaìṣìgùn, òun ni òrìṣà tí ń tú àṣírí gbogbo ohun tó pamọ́ sí ìkọ̀kọ̀. Ọba àti àwọn ìgbìmọ̀ rẹ̀ rí i pé Ọ̀sanyìn nìkan ló lè kojú èèmọ̀ tó wà lóko oníkàn yìí; wọ́n ránṣẹ́ sí i pé kó wá bá wọn mú ìgárá náà tí ń jí ìgbá onígbàá jẹ tó tún ń dẹ́rùbà olóko. Ọ̀sanyìn dé, ó yanbọ, àwọn ìlú san án. Ó múra, ó gbé ẹwìrì rẹ̀ àti

òòlù rẹ̀ dání, ó tẹ̀lé bàbá oníkàn; àwọn oníṣègùn, àwọn ọdẹ àti àwọn ará ìlú mìíràn tó fẹ́ ṣe ọ̀fíntótó, àwọn má-mójú-mi-débẹ̀ gbogbo ló tẹ̀lé wọn.

Nígbà tí wọ́n dé oko, Ọ̀sanyìn dáná àgbẹ̀dẹ, ó fi òòlù sí i, ó fínná mọ́ ọ, òòlù gbóná, ó rẹ̀ dòdò; Ọ̀sanyìn sọ fún bàbá oníkàn kó sọ bó ti ń sọ, òun náà bẹ̀rẹ̀ èpè, ó ń ṣẹ́ ẹ léjìléjìdà. Alábahun tún dáhùn nínú oko pé:

*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*
*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*
*Ìwọ ká, èmi ká,*
*Kínìnrínjingbin*
*Tèmi ṣe lè dèpè?*
*Kínìnrínjingbin*
*Èpè kan ò p'Ahun,*
*Kínìnrínjingbin*
*Oníkàn yìí jingbin,*
*Kínìnrínjingbin*

Gbogbo àwọn tó tẹ̀lé Ọ̀sanyìn wá ti sálọ, àṣubúlébú-n-tẹ̀be agbádá àwọn babaláwo ń fẹ́ riyẹriyẹ tẹ̀lé wọn lẹ́yìn, gèlè àwọn obìnrin tú, ọrùn nìkan ló dá a dúró, etí rẹ̀ méjéèjì ń fẹ́ lẹ́lẹ́ tẹ̀lé wọn lẹ́yìn bí àsìá ìdí ọkọ̀ ti ń rèlùú òyìnbó; sálúbàtà ẹlòmíràn ti fò sọnù, ẹsẹ̀ kan ṣoṣo ló bá a délé. Ṣùgbọ́n Ọ̀sanyìn kò yísẹ̀, ó faraṣoko, ó ń sọ́ ìgbà tí olè náà yóò bẹ̀rẹ̀ sí í ká ìgbá yìí.

Nígbà tí Ìjàpá rí pé ohun gbogbo ti pa lọ́lọ́, ó ṣebí gbogbo wọn ti sálọ, ó jáde, ó bẹ̀rẹ̀ mú ìgbá ká.Ọ̀sanyìn rọra ń yọ́ gúlọ́gúlọ́ tẹ̀lé e lẹ́yìn tòun ti òòlù tó ti bẹ yòyò lọ́wọ́; bó ti dé ẹ̀yìn Ìjàpá, àfi ṣìn-ìn-ìn, ló tẹ̀ ẹ́ bọ̀ ọ́ lọ́rùn.Ìjàpá kò lè dún pọ́bọ́, ó kú pátápátá.Ọ̀sanyìn bá gbé òkú rẹ̀ lọ sọ́dọ̀ ọba. Ọba ní kíỌ̀sanyìn máa gbé e lọ, àtòkú àtàáyè rẹ̀, Ọ̀sanyìn lóun tí pinnu àti fi olè náà fún un tẹ̀lẹ̀. Torí náà kí Ọ̀sanyìn lọ ṣe òkú Abahun bó ti wù ú.

Inú Ọ̀sanyìn dùn, díndín ló lọ dín Ìjàpá jẹ o. Látọjọ́ yìí ni wọ́n ti ń fi'Ìjàpá bọ Ọ̀sanyìn o, tí wọ́n sì ń pe Ìjàpá ní 'ẹran ọ̀sanyìn o'.

Olè àti àṣejù ló pa Ìjàpá o; ìwà tí ò sunwọ̀n, ẹ̀ jù ú lẹ̀ o.

*Ìdí àlọ́ mi rèé gbáǹgbáláká;*
*Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà;*
*Bí n bá purọ́, kágogo ẹnu mi má ròó,*
*Bí n ò bá purọ, kágogo ẹnu mi ró lẹ́ẹ̀mẹta –*
*Ó di …pó….pó….pó!*

Orísun ìtàn: Babalọla (1973)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìtàn yìí, Ìjàpá náà tún ni ẹ̀dá-ìtàn gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú ìtàn méjì àkọ́kọ́ ní abẹ́ ìpín kínní àti ìkejì. Alábahun fi ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ jí ikàn ní oko Baba oníkàn. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó yí ohùn padà láti kọ orin abàmì tí ó dẹ́rù ba bàbá oníkàn àti gbogbo ará ìlú. Ṣùgbọ́n àṣejù àti ojúkókòrò ni ó pa Ìjàpá nígbẹ̀yìn.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Ọ̀nà wo ni Ìjàpá gbà tó fi ń jí ikàn baba oníkàn?
2. Ṣe àgbéyẹ̀wò orin inú àlọ́ yìí. Ẹ̀ẹ̀melòó ni orin yìí wáyé nínú àlọ́ yìí? Iṣẹ́ wo ni orin ń ṣe nínú àlọ́? Wo módù kejì, ìpín kínní fún ìtọ́sọ́nà.
3. Nínú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a yẹ̀wò ní Módù kẹta, ìpín kínní, èwo nínú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ yìí ló rọ̀mọ́ ìtàn tí o kà yìí.
4. Ṣé òótọ́ ni pé àbùdá ìhun ìtàn 'àṣeṣetúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀' jẹyọ nínú ìtàn yìí? Tó bá jẹ́ lóòótọ́, lọ́nà wo ni èyí gba jẹyọ?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Babalọlá, A. (1979) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá,* Apá Kejì. Ibadan: University Press Ltd.

# ÌPÍN KẸRIN: ÌJÀPÁ, AJÁ, ẸKÙN ÀTI ỌDẸ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kíka Ìtàn Ìjàpá, Ajá, Ẹkùn àti Ọdẹ
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Wo ìfáárà abẹ́ ìpín kínní

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Èyí kò yàtọ̀ sí ti ìpín kínní

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Ẹranko mélòó ló wà nínú ìtàn yìí?
2. Ẹ̀dá-ìtàn mélòó ló wà nínú àkọlé ìtàn náà?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ka ìtàn inú ìpín yìí – Ìtàn Ìjàpá, Ajá, Ẹkùn àti Ọdẹ

*Apàlọ́:* *Àlọ́ o!*
*Àwọn Jànmọ̀:* *Àlọ́!*
*Apàlọ́:* *Àlọ́ mi dá fìirìgbágbòó, ó dálérí Ìjàpá, Ajá, Ẹkùn àti Ọdẹ*

Ní ìgbà láéláé, Ẹkùn, Ìjàpá àti Ajá, inú igbó kan náà ni wọ́n ń gbé. Ẹkùn jẹ́ àgbẹ̀, ó gbin ọ̀gẹ̀dẹ̀, ilá, ẹ̀fọ́, iṣu, ẹ̀gẹ́, àgbàdo àti oríṣiríṣi nǹkan tí ẹnu ń jẹ. Gbogbo ohun ọ̀gbìn rẹ̀ ló ṣe dáadáa: iṣu rẹ̀ ta àta-sán-ebè, àgbàdo rẹ̀ yọmọ bọ̀kùàbọ̀kùà, erèé rẹ̀ so jìnwìnnì, ìgbá-ikàn rẹ̀ so dọ̀kìàdọ̀kìà, ó so àsokanlẹ̀, gbogbo rẹ̀ dára.

Ìjàpá rèé, ọ̀lẹ ni, ẹni tí kò bá sì ṣiṣẹ́ ti ń fẹ́ jẹun dandan ni kólúwarẹ̀ jalè; olè ni Ìjàpá, oko-olóko ló ti ń kórè ohun tí yóò jẹ.

Ní ọjọ́ kan, Ìjàpá fẹ́ lọ jí irè-oko Ẹkùn, ó mọ̀ pé bí Ẹkùn bá mú òun, pẹ́rẹ́pẹ̀rẹ̀ ni yóò fa òun ya, ó lọ bá Ajá, ó bẹ̀ẹ́ kí ó bá òun lọ sí oko òun.

Ajá rèé, ọ̀tá ni òun àti Ẹkùn nítorí Ẹkùn féràn àtipa Ajá jẹ. Ìjàpá ń ta ọgbọ́n àtifi orí Ajá fún Ẹkùn fọn fèrè; ó rò nínú ara rẹ̀ pé bí òun bá lè tan Ajá dé ibùdó Ẹkùn, òun á tì í mọ́lé, bí ẹkùn bá tilẹ̀ dé, òun á sọ pé Ajá lòun múwá fún un gẹ́gẹ́ bí nǹkan àlejò, yóò dáríjì òun. Ajá kò mọ̀ pé oko Ẹkùn ni Ìjàpá ń tan òun lọ, ó tẹ̀lé e ní ìrètí pé oko Ìjàpá lòun ń lọ. Nígbà tí wọ́n dé oko Ẹkùn, wọ́n kò bá Ẹkùn lóko. Ìjàpá bẹ̀rẹ̀ sí í bẹ́ ọ̀gẹ̀dẹ̀, ó ń wa iṣu, ó ń fẹ́ ẹ̀fọ́, ó ń já erèé, ó ń re ata, kò sí irè-oko kan tó wà ní oko Ẹkùn tí Ìjàpá kò jí.

Nígbà tó pẹ́, ó di gbogbo ohun tó jí yìí jọ, ó ní kí Ajá wá bá òun gbé díẹ̀, Ajá bá a gbé e. Nígbà tí wọ́n gbérù tán tí wọ́n wo iwájú báyìí, Ẹkùn ni wọ́n rí tó ń sáré bọ̀ takọtakọ. Bí Ajá ti rí Ẹkùn báyìí, jẹbẹtẹ gbọ́mọ lé e lọ́wọ́, ó bẹ̀rẹ̀ sí í gbọ̀n.

'Ìjàpá, ṣebí ó sọ fún mi pé oko rẹ là ḿbọ̀, àṣéè oko Ẹkùn ni. O wá tàn mí fún Ẹkùn pajẹ ni.'

'Yára sápamọ́ sẹ́yìn ọ̀gẹ̀dẹ̀ yìí, kò ní rí ọ. Ẹkùn kàn ń kọjá lọ nítirẹ̀ ni.'

Ajá ju ẹrù sílẹ̀ pẹ̀ẹ̀, ó sápamọ́ sí ẹ̀yìn igi ọ̀gẹ̀dẹ̀, ó ń fọkàn rẹ̀ gbàdúrà pé kí Ọlọ́run yọ òun lọ́wọ́ Ẹkùn o. Jẹ́jẹ́ lòun jókòó sílé òun tí Ìjàpá ní kóun wá kálọ sí oko o, òun kò mọ̀ pé Ẹkùn ni yóò tan òun fún pajẹ o. 'Ìwọ Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá, ìwọ ló dá mi tí o sì dá Ẹkùn yìí, má ṣài yọ mí nínú ewu yìí o, má jẹ́ kí ń dìjẹ fún Ẹkùn lónìí o.

Nígbà tí Ajá ṣì ń gbàdúrà báyìí, Ẹkùn ti dọ́dọ̀ Ìjàpá, ó bí i ohun tó wá mú nínú oko òun. Ìjàpá dáhùn pé, 'Kábíyèsí, olówó mi, ọkọ mi, má bá mi wí, èmi kọ́ ni mo rán ara mi wá, rírán ni wọ́n rán mi, n kò sì mọ̀ pé oko yín ni. Ẹ jọ̀wọ́ ẹ foríjì mí, n ò ní dé sàkání oko yín mọ́.'

'Wọ́n rán ọ ni! Ta ni rán ọ wá kórè gbogbo iṣẹ́ tí mo fi òógùn ojú mi ṣe?'

> 'Ajá ni!'
> 'Ajá!Ajá tàbí kínla!'
> 'Ajá ni; a jìjọ wá náà ni, mo rò pé oko rẹ̀ ni, n kò mọ̀ pé tiyín ni, olúwa mi.'
> 'Níbo l'Ajá ọ̀hún wà?'

'Òun ló lẹ̀ sẹ́yìn ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà lọ́hùn-ún nì. Ìgbà tí ó rí yín náà ni ó sápamọ́ síbẹ̀. N kò lè sáré ló jẹ́ kí ẹ rí mi mú ní ìrọ̀wọ́rọsè báyìí.'

Nígbà tí Ajá gbọ́ pé Ìjàpá ti fi òun hàn, tí ó sì purọ́ ràbàtà báyìí mọ́ òun, ó bú eré dà sílẹ̀, ìjáfara léwu, bí òun kò bá sá, òun di ìjẹ fún Ẹkùn nìyẹn. Bí Ẹkùn ti rí Ajá lọ́ọ̀kánkán báyìí, ó fi Ìjàpá sílẹ̀, ó bẹ́ tẹ̀lé e, ó di púrà, ó di kìtà kìtà kìtà, wọ́n ń sáré lọ lẹlẹ, gìgìrísẹ̀ wọn ń kan wọ́n nípàkọ́ bí wọ́n ti ń sáré lọ. Ajá ń sá àsálà fún ẹ̀mí rẹ̀, Ẹkùn ń sáré oúnjẹ, wọ́n ń forí

rún oko lọ girigiri.Ìjàpá nítirẹ̀ ti kó èyí tí yóò jẹ nínú irè-oko tó kórè, ó bá ẹsẹ̀ rẹ̀ sọ̀rọ̀, ó gba àbùjá lọ sí ihò àpáta tí ó ń gbé.

Ajá ń sáré lọ, ó la ẹnu sílẹ̀, ó ń mí hẹlẹhẹlẹ, àárẹ̀ ti ń mú u, síbẹ̀ ó forítìí, tí ó bá dúró, Ẹkùn á fi í jẹ, òun á kúkú sáré àsákú tàbí àsálà. Nígbà tó yá, ó rí ọlọ́dẹ kan lọ́ọ̀kankan, eléyìíni gègùn, ó ń dèsun ẹranko, Ajá fi òpópó ọ̀dọ̀ rẹ̀ ṣọ̀nà, ó ń sáré lọ gbururu, ó ń ké pé, 'Gbà mí, ọdẹ, ọlọ́dẹ gbà mí, n ó dẹrú rẹ, Ẹkùn ni ń lé mi bọ̀! Gbà mí, mo sá di ọ́.Gbà mi o máa mú mi relé, gbà mi o rà mí!'

Ojú ti ọlọ́dẹ gbé sókè báyìí, Ẹkùn ló rí tí ń sáré kíkankíkan tẹ̀lé Ajá. Kíá ló bá táwọ́ sí ìbọn rẹ̀, ó di gàà! Ìbọn mú Ẹkùn lẹ́sẹ̀, ẹsẹ̀ rẹ̀ kan dá, ó ṣẹ́rí padà, ó ń sá wọ̀nkúwọ̀nkú lọ.

Ajá ní òun kò lè gbé nínú igbó náà mọ́ nítorí Ẹkùn yóò máa ṣọ́ òun kiri ni, yóò sì wá pa òun jẹ lóru níbi yòówù kóun sá sí. Ìjàpá lè fi òun wá ojúrere lọ́dọ̀ Ẹkùn kí ó fi ibùdó òun hàn án. Torí náà ó sàn kí òun kúkú bá olóore òun lọ.

Láti ìgbà yìí ni Ajá ti ń bá ọlọ́dẹ rìn o, tí Ajá kò gbé inú oko mọ́ tó fi di ọ̀kan nínú àwọn ẹran ọ̀sìn nílé o.

*Ìdí àlọ́ mi rèé gbáńgbáláká;*
*Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà;*
*Bí n bá purọ́, kágogo ẹnu mi má ròó,*
*Bí n ò bá purọ, kágogo ẹnu mi ró lẹ́ẹ̀mẹta –*
*Ó di …pó….pó….pó!*

Orísun ìtàn: Babalọla (1979)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ìjàpá tan Ajá lọ jí ohun ọ̀gbìn ní oko Ẹkùn. Ojúkòkòrò Ìjàpáni ó mú Ẹkùn ká wọn mọ́ inú oko rẹ̀. Ìjàpá purọ́ mọ́ Ajá lọ́dọ̀ Ẹkùn pé Ajá ni ó rán òun wá jalè lóko Ẹkùn. Ó sì fi ibi tí Ajá sá pamọ́ sí han Ẹkùn. Ẹkùn lé Ajá láti pajẹ. Ó pàdé Ọlọ́dẹ.Ọlọ́dẹ sì gba Ajá sílẹ̀ lọ́wọ́ Ẹkùn.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Gẹ́gẹ́ bí o ṣe kà nínú ìtàn yìí, irú ẹ̀dá wo ni Ìjàpá?
2. Dárúkọ ohun ọ̀gbìn márùn-ún tí ó wà nínú oko Ẹkùn.
3. Ta ni ó gba Ajá sílẹ̀ lọ́wọ́ Ẹkùn?
4. Kí ni ìdí tí Ajá fi jẹ ẹran ọ̀sìn nílé?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Babalọlá, A. (1979) *Àkójọpọ̀ Àlọ́ Ìjàpá,* Apá Kejì. Ibadan: University Press Ltd.

# MÓDÙ KARÙN-ÚN: ÀTÚPALẸ̀ ÀṢÀYÀN ÀWỌN ÀLỌ́ OLÓROGÚN

## TÀBÍ ÀLỌ́ MÌÍRÀN

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kíka ìtàn Orogún Méjì àti Ọkọ wọn
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Nínú Módù yìí, a ó ṣe àtúpalẹ̀ àwọn àṣàyàn àlọ́ olórogún tàbí àwọn àlọ́ mìíràn tí ó yàtọ̀ sí àlọ́ Ìjàpá. A ṣe àkójọpọ̀ àwọn àlọ́ wọ̀nyí fún akẹ́kọ̀ọ́ láti kà ní àkàgbádùn àti láti ṣe àmúlò àwọn iṣẹ́ tí a ti ṣe ní abẹ́ módù kínní títí dé ìkẹta fún ìtúpalẹ̀ àwọn àlọ́ yìí.

Ìpín kínní: Ìtàn Orogún Méjì àti Ọkọ wọn
Ìpín kejì: Ìyáálé Gbé Ọmọ Ìyàwó Rẹ̀ Sínú Ọtí
Ìpín kẹta: Ìyáálé Roko Tán
Ìpín kẹrin: Tanímọ̀la àti Orogún Ìyá Rẹ̀

Títí di ìsinyìí, o kò ní àǹfààní àti ka àwọn ìtàn mìíràn tàbí àlọ́ olórogún ní kíkún. Lẹ́yìn kíka ìtàn yìí ní àkàgbádùn, ìwọ yóò dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó rọ̀ mọ́ ìtàn yìí èyí tí yóò fi ìyénisí àti ìtúpalẹ̀ ìtàn náà hàn.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ yóò lè:

(i) ka ìtàn náà fúnra rẹ̀ ní àkàgbádùn
(ii) dáhùn àwọn ìbéèrè tó rọ̀ mọ́ àwọn ìtàn náà.
(iii) mọ bí a ṣe ń ṣe àtúpalẹ̀ àlọ́ nípa ṣíṣe àmúlò àwọn ohun tí a ti gbéyẹ̀wò ní Módù 1 – 3.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Irú àlọ́ wo ni à ń pè ní àlọ́ olórogún?

# 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

## 4.1 Ka ìtàn Orogún méjì àti Ọkọ wọn

*Apàlọ́:* *Àlọ́ o!*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Àlọ́!*
*Apàlọ́:* *Àlọ́ mi lérí fùùrùgbágbòó*
*Agbálọ̀ọ́:* *Kó máà gbágbo ọmọ mi lọ*
*Apàlọ́:* *Àlọ́ mi lérí kò lérí,*
*Àlọ́ mi lérí àwọn ìyàwó méjì àti ọkọ wọn*

Ọkọ wọn jẹ́ ẹni tí máa ń ṣọdẹ lọ sí ìdálẹ̀.Bí ó bá sọdẹ lọ nígbà mìíràn, ó le lo oṣù mẹ́ta.Èyí sì ti mọ́ àwọn ìyàwó rẹ̀ lára. Ṣùgbọ́n bí ó bá ń ti ìdálẹ̀ bọ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ aláàárù ló máa ń gbà tí yóò ru ẹrantó ti pa tẹ̀lé e. Ó ti pa erin rí. Ó sì ti pa ẹfọ̀n. Bẹ́ẹ̀ sì ni ọwọ́ rẹ̀ ti tẹ kìnnìún lẹ́ẹ̀kan. Ojú ogúnjọ tí ọdẹ aperin bá ti ìgbẹ́ ọdẹ dé àwọn obìnrin rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ẹ̀bùn Ọlọ́run wọ́n sì máa ń ṣọdún ẹran ni. Àwọn ìyàwó kì í wọ́n ní ìdí ààrò. Bí wọ́n ṣe ń sè ni wọ́n máa ń sọ̀.

Oríṣiríṣi ènìyàn ló máa ń wá kí ọdẹ yìí bí ó bá ti dé. Ọdẹ náà sì jẹ́ ẹni tí ó lawọ́ dáadáa, gbogbo àwọn àlejò wọ̀nyí ló máa wá ń fún un ní nǹkan. Oríṣiríṣi ìròyìn ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn tí ó ti kúrò nílé ni wọ́n máa ń sọ fún un. Ìròyìn tí wọ́n sì fún un nípa ìyáálé rẹ̀ kì í ṣe èyí tó rẹwà. Wọ́n máa ń fi yé e pé bí ó bá ti kúrò nílé tán ni ìyáálé rẹ̀ máa ń ṣe àgbèrè káàkiri ìlú. Ṣùgbọ́n ohun tí ó jọ ni lójú ni pé ìyáálé yìí ló máa ń sọ fún ọkọ wọn pé ìwà àgbèrè ti wọ ìyàwó òun lẹ́wù àti pé bí ọkọ bá ti kúrò nílé tán kò lówò méjì lẹ́yìn ìṣekúṣe.

Ọkọ yìí ní àléébù kan, ìwà náà sì ni pé ó fẹ́ràn ìyáálé rẹ̀ ju ìyàwó lọ. Ó sì jẹ́ kí èyí hàn sí àwọn méjéèjì. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé bí ìyáálé bá ti ro ẹjọ́ pé ìyàwó ń ṣe àgbèrè kì í bojú wẹ̀yìn mọ́ ti fi máa ń kó ẹgba yá a. Ṣùgbọ́n nígbà tí ó lọ sí oko ọdẹ ní àsìkò kan, ó pẹ́ ju bí ó ṣe máa ń pẹ́ lọ, odidi ọdún mẹ́ta ló lò ní ìrìn àjò. Ní ààrin ọdún mẹ́ta yìí, ó bá àwọn ẹranko tí ń ṣeré ìfẹ́ tó ẹ̀ẹ̀mejì. Gẹ́gẹ́ bí àṣà Yorùbá, bí èyí bá sì ṣẹlẹ̀ sí ọdẹ kan àpẹẹrẹ pé ìyàwó rẹ̀ ń ṣàgbèrè ni ó jẹ́.

Nígbà tí ó rí àmì yìí ní ìgbà mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó bá fi ọ̀rọ̀ lọ ọdẹ ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ kan. Eléyìí ló wá bèèrè bóyá ó lẹ́ran ọ̀sìn nílé. Ọdẹ sì dáhùn pé òun ní àgbò kan. Ọdẹ wá fi ìdí òògùn kan hàn án. Ó ní bí ó bá ti fi í sí ara Àgbò náà kí ó sọ pé kí àwọn ìyàwó rẹ̀ máa fún Àgbò náà ní ewé ọdán ní ọ̀kọ̀ọ̀kan kí wọ́n sì máa kọrin báyìí pé:

*Apàlọ́:* *Gbewé mi, gbewé mi jẹ*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Àgbò, gbewé mi jẹ*
*Apàlọ́:* *Ọdún mẹ́ta ọkọ ti lọ*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Àgbò, gbewé mi jẹ*

*Apàlọ́:* *Èmi ò rìnà bọ́kùnrin pàdé*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Àgbò, gbewé mi jẹ*
*Apàlọ́:* *Ọkùnrin ò tẹ́ni fún èmi sùn rí*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Àgbò, gbewé mi jẹ*

Bí ọkọ ṣe délé, ó ní sùúrù, ó ní kí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìyàwó òun méjéèjì ṣe pẹ̀pẹ́fúúrú fún òun fún bí ọjọ́ mẹ́ta ni ó bá dán òògùn náà wò. Ìyàwó ni ó kọ́kọ́ já ewé ọdán tí ó sì kọrin òkè yìí, kíá ni Àgbò gba ewé rẹ̀ jẹ. Ṣùgbọ́n nígbà tí ó di orí ìyáálé ni Àgbò kò bá gba ewé rẹ̀ jẹ. Ṣé ìwà àgbèrè sì jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ ńlá ní ayé ìgbà náà, kò jọ òde òní tí àwọn kan fi ń sánjú oge, òfin ìlú wọn ni pé pípa ni wọ́n máa ń pa obìnrin tí wọ́n bá ti mú fún ìwà àgbèrè. Báyìí ni wọ́n pa ìyáálé alágbèrè náà.

Ẹ̀kọ́ ìtàn yìí kọ́ wá pé kí á yẹra fún ìwà àgbèrè àti irọ́ pípa.

*Apàlọ́:* *Ibi tí mo dé nìyí tí mo dẹ̀yìn*
*Kí àlọ́ mi gba orógbó jẹ*
*Kí ó má ṣe gba obì jẹ*
*Orógbó á gbó wọn sáyé*
*Obì á bì wọ́n sọ́run*
*Bí mo bá purọ́*
*Kí agogo ẹnu mi máà ró ní ẹ̀ẹ̀mẹ́ta*
*Ṣùgbọ́n bí n kò bá parọ́*
*Kí ó ró*
*Ó di pó! pó!! pó!!!*
*Ó ró tàbí kò ró?*

*Àgbálọ̀ọ́:* *Ó ró.*
Orísun ìtàn: Ọ̀pádọ̀tun (1994)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Nínú ìtàn yìí, a rí ọ̀nà ìṣíde ìtàn náà èyí tí a ti fún wa ní àpẹẹrẹ irúfẹ́ rẹ̀ ní abẹ́ Módù kẹta. Lẹ́yìn èyí, a rí ìṣòro tó wà ní ilé olórogún àti ìwà àgbèrè tí ìyáálé hù. A lè sọ pé àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí ìtàn náà dá lérí ni ìwà àìṣòdodo àti ìwà àgbèrè èyí tí ìyáálé hù èyí tí ó fa ikú rẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí:

1. Iṣẹ́ wo ni ọkọ àwọn orogún méjì yìí ń ṣe?
2. Ṣe àpèjúwe ìwà ìyáálé inú ìtàn yìí.
3. Àwọn kókó wo ni ó jẹyọ nínú ìtàn náà?
4. Ọ̀nà wo ni ọkọ yìí gbà láti mọ òótọ́ láàárín ìyáálé àti ìyàwó?
5. Àwọn ẹ̀dá-ìtàn mélòó ló wà nínú ìtàn yìí?

6. Kí ni ìyàtọ̀ láàrin bátànì ìparí àlọ́ yìí àti èyí tí a gbéyẹ̀wò ní Módù kẹta, Ìpín kejì?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ibadan: Y-Books.

# ÌPÍN KEJÌ: ÀTÚPALẸ̀ ÌTÀN ÌYÁÁLÉ GBÉ ỌMỌ ÌYÀWÓ RẸ̀ SÍNÚ ỌTÍ

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kíka ìtàn Ìyáálé Gbé Ọmọ Ìyàwó Rẹ̀ Sínú Ọtí
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Wo ìfáárà abẹ́ ìpín kínní ní Módù yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ

Wo èròǹgbà abẹ́ ìpín kínní ní Módù yìí bákan náà

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kí ni ìtumọ̀ ìyààlé?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ka ìtàn Ìyáálé gbé ọmọ iyàwó rẹ̀ sínú ọtí

*Apàlọ́:* *Àlọ́ o!*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Àlọ́!*
*Apàlọ́:* *Àlọ́ mi lérí fùùrùgbágbòó*
*Agbálọ̀ọ́:* *Kó máà gbágbo ọmọ mi lọ*
*Apàlọ́:* *Àlọ́ mi lérí kò lérí,*
*Ó lérí ọkùnrin àgbẹ̀ kan tó fẹ́ràn iṣẹ́ oko.*

Ó fẹ́ ìyàwó àkọ́fẹ́ ní rògbàrògbà. Ó ṣe gbogbo ohun tí wọn ń ṣe lé aya lórí kí wọ́n tó sin Èjìdé fún un tìlù tìfọn. Ẹnu kọ ìròyìn ní ọjọ́ ìgbéyàwó wọn. Ọkùnrin àgbẹ̀ yìí náwó gidi ní ọtíkà tẹ́ lọ́jọ́ náà, kò níyì kankan. Ọtí ṣẹ̀kẹ̀tẹ́ pọ̀ bí omi òkun. Bẹ́ẹ̀ sì ni kì í ṣe àsìkò ọtí òyìnbó ni àgbẹ̀ yìí kì bá rà. Ṣùgbọ́n ọtí àgàdàngidi náà wá sí ibi ayẹyẹ.

Ọdún kan lẹ́yìn ìgbéyàwó àgbẹ̀ àti Èjìdé, ìròyìn ìyàwó yìí kò tán nílẹ̀. Nígbà tí ó tilẹ̀ yá ni wọ́n bá sọ ọ́ di àṣà, wọn á sì sọ pé ináwó kan kọyọyọ bí ìnáwó ìgbéyàwó Èjìdé àti bàbá àgbẹ̀.

Ṣé ènìyàn kò le gbọ́n títí kí tirẹ̀ máà bá a. Bẹ́ẹ̀ sì ni kò sí ẹ̀dá tí kò ní ìṣòro tirẹ̀, àní kálukú ló ní tirẹ̀ lára. Agbọ́n dára títí, oró ńkọ́, ìkamùdù sunwọ̀n lóòótọ́ ó kù sí ibi òórùn. Àní bí ẹmọ́ òyìnbó ṣe yáàyì tó àìnírù ni àléébù ẹranko. Èjìdé àti bàbá àgbẹ̀ fẹ́ràn ara wọn bí ẹ̀mí. Wọ́n lóúnjẹ nílé, wọ́n láṣọ lára wọn sì ní owó lápò lápò.Ṣùgbọ́n ewúrẹ́ tí bàbá àgbẹ̀ tún fẹ́ràn lẹ́yìn Èjìdéló ṣe ẹ̀kẹta wọn nínú ilé. Nígbà tí ó sì di ojú ọdún kẹsàn-án tí Èjìdé kò rí oyún,ni bàbá àgbẹ̀ bá fẹ́ ìyàwó tuntun lé e.

Èjìdé àti ìyàwó kékeré tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Mopé fẹ́ràn ara wọn. Irú aṣọ kan náà ni wọ́n máa ń wọ̀, bẹ́ẹ̀ sì ni gèlè wọn kì í yàtọ̀. Kò sẹ́ni tó le rí wọn kí ó pè wọ́n ní obìnrin ọkọ kan náà. Ńṣe ni wọn ń hùwà bíi ọmọ ìyá kan náà. Nígbà tí yóò sì fi tó ọdún kan tí Mopé délé ó ti lóyún. Ó sì fi oyún náà bí ọmọkùnrin kan làǹtìlanti. Ńṣe ni Èjìdé ń ra ọmọ yìí mẹ́yìn kiri. Ṣàṣà ènìyàn ló sì mọ̀ pé kì í ṣe òun ló bí i. Àṣé ìfẹ́ tí a fẹ́ adìẹ kò dénú ni ìfẹ́ tí Èjìdé ní sí ọmọ ìyàwó rẹ̀. Ojú ayé lásán ló ń ṣe, kò gbàdúrà kí ọmọ náà ó yè.

Ọtíkà ni Èjìdé máa ń tà. Ìkòkò aládi ńlá ló fi máa ń dáná rẹ̀. Bàbá tó àsìkò tó yẹ kí ó ti oko dé ni wọn kò róye bàbá. Nígbà tí wọ́n retí rétí tí etí di rere ni ìyàwó kékeré tí í jẹ́ Mopé bá ní òun tọ ẹsẹ̀ ọkọ lọ sí oko. Kín ni Mopé kúrò ní ilé sí ni Èjìdé bá gbé ọmọ, ó di sọ́dù nínú iná ọtí.

Nígbà tí Mopé yóò fi rin ibùsọ̀ méjì ló bá pàdé ọkọ rẹ̀ lọ́nà. Ọkọ ni òun pa àgbọ̀nrín ni òun ń ṣaáyan rẹ̀ ló jẹ́ kí òun pẹ́. Báyìí ni Mopé àti ọkọ fi ìdùnnú ru ẹran àgbọ̀nrín padà sí abúlé wọn. Ẹ̀rín àti ọ̀yàyà sì ni Èjìdé fi kí àwọn méjéèjì kú àbọ̀.

Bí wọ́n ṣe simi díẹ̀ tán ni ìyàwó bá wọ ìyẹ̀wù lọ láti yẹ ọmọ rẹ̀ wò níbi tí ó tẹ́ ẹ sí ni ọmọ bá di àwátì. Èjìdé sì sọ pé òun kò mọ ibi tí ọmọ wà. Báyìí ni wọ́n ṣàà wá ọmọ títí tí wọn kò sì rí aáràfi ọmọ. Ṣé amòòkùn jalè, bí ọba ayé kò rí i, ọba ti ọ̀run ń wò ó. Àṣé gbogbo ìgbà tí Èjìdé fi ń gbé ọmọ jù sínú ìkòkò ọtí ni ewúrẹ́ ọkọ wọn ń ṣọ́ ọ.

Lẹ́yìn tí wọ́n ti wá ọmọ títí tí agara sì ti dá wọn ni ewúrẹ́ bá bẹ̀rẹ̀ sí kọrin báyìí pé:

| | |
|---|---|
| *Apàlọ́:* | *Orogún burúkú* |
| *Àgbálọ̀ọ̀:* | *Kónkolà kónkòlá kó-n-kó* |
| *Apàlọ́:* | *Ó gbọ́mọ sọ sọ́tí* |
| *Àgbálọ̀ọ̀:* | *Kónkolà kónkòlá kó-n-kó* |
| *Apàlọ́:* | *Bó bá jọ bí irọ́ ẹ wo inú ọtí wò* |
| *Àgbálọ̀ọ̀:* | *Kónkolà kónkòlá kó-n-kó* |

Bí ewúrẹ́ yìí ṣe ń kọrin ni Èjìdé ní "Ẹ̀ ò wa, wo ewúrẹ́ adásínilọ́rùn, ọjọ́ wo lòun wá gbọ́mọ sọ sínú ọtí?" Ṣùgbọ́n ewúrẹ́ kò yéé kọrin. Báyìí ni ọkọ wọn ṣe kó àwọn ìyàwó méjéèjì àti ewúrẹ́ dé ààfin ọba. Bí ewúrẹ́ sì ṣe kọrin yìí ni ọbá ní kí àwọn ìránṣẹ́ rẹ̀ lọ gbé ìkòkò ọtí náà wá. Nígbà tí wọ́n sì wo inú ìkòkò ọtí, òkú ọmọ ni wọ́n bá níbẹ̀. Báyìí ni ọba pàṣẹ pé kí wọ́n bẹ́ Èjìdé lórí ní ìdí ògún.

Ẹ̀kọ́ tí ìtàn yìí kọ́ wa ni pé kò yẹ kí á máa ṣe ìkà àti ìlara. Kò sí ohun tí Ọlọ́run ṣe fún ẹnìkan tí kò lè ṣe fún àwa náà, ṣùgbọ́n kí á máa dúró de àsìkò tiwa.

*Apàlọ́:* *Ìdí àlọ́ mi rèé gbáǹgbáláká;*
*Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà;*
*Kí ọ̀fọ́n-ọ̀n gun àjà*
*Kí ó gbé ẹgbàá kò mí*
*Kí n fi agogo ẹnu pópó*
*Ogbó orógbó ni kí n gbó*
*Kí n má ṣe gbó ogbó obì*
*Ṣebórógbó ní kí n gbó ni sáyé*
*Obì níí bì wọ́n sọ́run*
*Bí mo bá dé ìdí ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà*
*Kí n bímọ gbàǹgbà*
*Bí mo bá purọ́*
*Kí agogo ẹnu mi máà ró ní ẹ̀ẹ̀mẹta*
*Ṣùgbọ́n bí n kò bá parọ́ kí ó ró*
*Ó di pó! pó! pó!*
*Ó ró tàbí kò ró?*

*Àgbálọ̀ọ́:* *Ó ró.* Orísun ìtàn: Ọ̀pádọ̀tun (1994)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ìtàn yìí jẹ́ ìtàn olórogún. A sì rí ọ̀kan lára ìṣòro tó wà ní ilé olórogún. Èyí ni ìlara ìyáálé sí ìyàwó. Ìyáálé kò bímọ ṣùgbọ́n ìyàwó bí. Ìfẹ́ ojú ni ìyáálé ní sí ìyàwó. Nígbà tí ó yá ó fi ìwà rẹ̀ tòótọ́ hàn nípa pípa ọmọ ìyàwó rẹ̀ ní ọ̀nà búburú.Ó gbé ọmọ náà jù sínú orù tí a fi ń se ọtí. Ọba sì dájọ́ ikú fún un fún ìwà ọ̀dájú yìí. Wọ́n bẹ́ orí ìyáálé ní ìdí ògún.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí:

1. Kí ni orúkọ ìyáálé àti ìyàwó nínú ìtàn yìí?
2. Ọdún mélòó ni ìyáálé lò nílé ọkọ láìbímọ?
3. Iṣẹ́ wo ni ìyàwó ń ṣe?
4a. Ǹ jẹ́ orin inú àlọ́ yìí rọ̀ mọ́ kókó ìtàn náà?

b. Ní ọ̀nà wo?
5. Ṣe àpèjúwe ìwà ìyáálé yìí.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ibadan: Y-Books.

# ÌPÍN KẸTA: ÌTÀN ÌYÁÁLÉ ROKO TÁN

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Kíka ìtàn Ìyáálé Roko Tán ní àkàyé
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Wo ìfáárà abẹ́ ìpín kínní ní Módù yìí.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Wo èròǹgbà abẹ́ ìpín kínní ní Módù yìí bákan náà

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

Dárúkọ ìwà mẹ́ta tí Yorùbá bu ẹnu àtẹ́ lù.

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ka ìtàn ìsàlẹ̀ yìí - Ìyáálé roko tán

*Apàlọ́:* *Ààlọ́ o!*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Ààlọ́!*
*Apàlọ́:* *Ní ọjọ́ kan*
*Agbálọ̀ọ́:* *Ọjọ́ kan ni òní jẹ́*
*Kọ́ba jẹ́ kó jẹ́ ọjọ́ rere fún wa*
*Apàlọ́:* *Ní ìgbà kan*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Ìgbà kan ń lọ,*
*Ìgbà kan ń bọ̀,*
*Ìgbà kan kì í tán láyé*
*Apàlọ́:* *Ọkùnrin kan wà tí ó ní ìyàwó kan.*

Ó fẹ́ ìyàwó rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe ń fẹ́ ìyàwó ní ayé ìgbà náà.Ìyàwó náà kò sì mọ ọkùnrin títí ó fi délé ọkọ. Ṣùgbọ́n níbi tí iṣẹ́ Olódùmarè jẹ́ àwámárìdìí sí, ìyàwó náà kò fi inú soyún bẹ́ẹ̀ ni kò sì fi ẹ̀yìn gbé ọmọ pọ̀n fódidi ọdún mẹ́wàá lẹ́yìn tí ó ti délé ọkọ.

Lẹ́yìn tí gbogbo aláwo ilé ayé ti ṣe é tì,ni wọ́n bá kọrí sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́run. Ọ̀run kò sì jìnnà sílé ayé báyìí nígbà náà, bí ènìyàn bá tètè lọ láàárọ̀ títí alẹ́ olúwarẹ̀ yóò dé.Nígbà tí wọ́n dé ọ̀dọ̀ Aṣẹ̀dá.Ó ní kí wọ́n ní sùúrù nítorí pé ọmọ tí ń bẹ nílẹ̀ kò dára. Ó ní ìṣènìyànṣẹranko ọmọ ni. Ó ní adìẹ pilẹ̀ ni, àmọ́ a tún máa mú àwọ̀ ènìyàn nígbà mìíràn. Tọkọ taya yìí ní kí Ọlọ́run ṣáà fún àwọn. Wọ́n ní ká rí ẹni báwí ṣàn ju àìrí báwí rárá. Olódùmarè ni ó dára kí wọ́n máa lọ, Òun yóò mú ìbéèrè wọn ṣẹ.

Báyìí ni àwọn méjéèjì ṣe padà sílé ayé. Ìyàwó kò mú oṣù náà jẹ lẹ́yìn èyí tí wọ́n dé tí ó fi lóyún. Lẹ́yìn oṣù kẹsàn-án ni ìyàwó náà bí obìnrin. Ọmọ náà dára ju ojo ilé tí mo lọ.Ó rí wiliki wiliki.Ó dúdú bí kóró iṣin.Nígbà tí yóó fi tó ogún ọdún tí a bí ọmọ náà, ó ti di ọmọge gidi ṣùgbọ́n àwọn òbí rẹ̀ kò tún gbọ́ mo-kó-ó ọmọ mìíràn mọ́.Gbogbo ènìyàn ló sì ń pòòyì ilé wọn láti fi ọmọ wọn saya. Bí ọmọbìnrin yìí ṣe dára tó, ó ní àléébù kan, èyí náà sì ni pé ó máa ń yí padà sí adìẹ nígbà mìíràn. Bí ó bá ti yí padà báyìí, àgbàdo ni àwọn òbí rẹ̀ máa ń fún un títí tí yóò tún fi padà sí ènìyàn.

Nígbà tí ọmọbìnrin tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Pẹrẹsẹkẹ rí ẹni tí ó wù ú láti fi ṣe ọkọ, àwọn òbí rẹ̀ sọ òótọ́ fún ọkùnrin náà.Ọmọbìnrin yìí ti wọ ọkùnrin náà lójú tí ó fi gbà láti fẹ́ ẹ ní ọ̀nàkọnà.Ó sì ṣe ìlérí pé gbogbo èèwọ̀ rẹ̀ lòun yóò máa pamọ́. Bí ìyàwó yìí ṣe délé ni ọkọ kìlọ̀ fún ìyáálé rẹ̀ pé kò gbọdọ̀ fi bú u àti pé kò gbọdọ̀ fún un ní oúnjẹ mìíràn lẹ́yìn àgbàdo lásìkò tí Pẹrẹsẹkẹ bá di adìẹ.

Nígbà tí Pẹrẹsẹkẹ yóò fi lo ogójì ọjọ́ nílé ọkọ, ìfẹ́ rẹ̀ ti kó sí ọkọ lórí, kò tilẹ̀ rójú ti ìyáálé rẹ̀ mọ́.Wọ́n sì ti bẹ̀rẹ̀ sí fi Pẹrẹsẹkẹ sílẹ̀ lọ sí oko. Ṣùgbọ́n bí wọ́n bá ti ń lọ sí oko ni wọn yóò fi ọmọbìnrin kékeré kan (ọmọ ìyáálé) tì í, àwọn yòókù yóò sì lọ sí oko.

Bí Pẹrẹṣẹkẹ bá ti rí i pé wọ́n lọ sí oko tán ni ó máa ń di adìẹ tí yóò sì máa kọrin báyìí pé:

| | |
|---|---|
| *Apàlọ́:* | *Ìyáálé roko tán* |
| *Agbálọ̀ọ́:* | *Pẹrẹsẹkẹ* |
| *Apàlọ́:* | *Bàbá roko tán* |
| *Agbálọ̀ọ́:* | *Pẹrẹsẹkẹ* |
| *Apàlọ́:* | *Mo wáá ráyè di gbàgbàká* |
| *Agbálọ̀ọ́:* | *Pẹrẹsẹkẹ* |
| *Apàlọ́:* | *Mo fò síhìn-ín fò sọ́hùn-ún* |
| *Agbálọ̀ọ́:* | *Pẹrẹsẹkẹ* |
| *Apàlọ́:* | *Ma fò pìì dadìẹ* |
| *Agbálọ̀ọ́:* | *Pẹrẹsẹkẹ* |

Báyìí ni Pẹrẹsẹkẹ yóò ṣe máa fò láti igi ọdán sí orí igi òro tí yóò máa ti orí àjà fò sí òrùlé títí yóò fi rẹ̀ ẹ́ tí yóò sì tún di ènìyàn padà.

Bí gbogbo wọn bá ti ti oko dé ni ọmọbìnrin tó dúró ti ìyàwó náà ń sọ gbogbo ohun tí ojú rẹ̀ tó fún ìyá rẹ̀ tí í ṣe ìyáálé Pẹrẹsẹkẹ. Ìyáálé yóò sì sọ fún ọkọ. Ṣùgbọ́n dípò kí èyí dín ìfẹ́ tí ọkọ ní sí Pẹrẹsẹkẹ kù, ńṣe ló túbọ̀ ń pọ̀ sí i. Èyí ló mú kí ìyáálé pinnu láti fi òpin sí ìfẹ́ ààrin Pẹrẹsẹkẹ àti ọkọ rẹ̀. Báyìí ló ṣe padà lọ́nà oko ní ọjọ́ kan tí ó parọ́ fún ọkọ pé orí ń fọ́ òun. Ó lúgọ sí ibi kan nínú ilé, ó sì ní sùúrù títí Pẹrẹsẹkẹ fi di adìẹ tó sì ń kọrin rẹ̀ kiri. Nígbà tí adìẹ náà bà sí ìtòsí ni ó bá fún un ní àmàlà jẹ. Jíjẹ tí adìẹ jẹ àmàlà tán ni kò bá le yí padà sí ènìyàn mọ́. Àwọn adìẹ gidi sì bẹ̀rẹ̀ sí ṣá a ní ara. Pẹrẹsẹkẹ ọjọ́ náà ló di Adìẹ aṣa. Ṣíṣá tí àwọn adìẹ fi ẹnu ṣá a lára ní ọjọ́ náà ló jẹ́ kí ara rẹ̀ rí ṣákaṣàka títí di òní.

Ẹ̀kọ́ tí ìtàn yìí kọ́ wa ni pé kí á má ṣe máa gba nǹkan bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀, ọmọ bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni Pẹrẹsẹkẹ. Ó sì tún kọ́ wa kí á máa hùwà aríyàwó-kọ-ìyáálé ènìyàn, ìwà ọkọ Pẹrẹsẹkẹ ló jẹ́ kí ìyáálé ta ìjàǹbá fún Pẹrẹsẹkẹ. Ó tún kọ́ wa pé kò yẹ kí á máa fi gbogbo inú wa han obìnrin. Bí ọkọ kò bá sọ èèwọ̀ Pẹrẹsẹkẹ fún ìyáálé rẹ̀ ni, kì bá ti lè ta ìjàǹbá fún un.

*Apàlọ́:* *Ìdí àlọ́ mi rèé gbáńgbáláká;*
*Ìdí àlọ́ mi rèé gbàǹgbàlàkà;*
*Kí ọ̀fọ́n-ọ̀n ó gàjà kó gbé ẹgbàá kò mí*
*Kí n fi agogo ẹnu pópó*
*Ogbó orógbó ni kí n gbó*
*Kí n má ṣe gbó ogbó obì*
*Orógbó ní í gbó ni sáyé*
*Obì níí bi ni sọ́run*
*Bí mo bá purọ́*
*Kágogo ẹnu mi má ṣe ró*
*Bí n kò bá parọ́*
*Kí agogo ẹnu mi ró*
*Ó di pó! pó! pó!*
*Ó ró tàbí kò ró?*
*Àgbálọ̀ọ̀:* *Ó ró!*

Orísun ìtàn: Ọ̀pádọ̀tun (1994)

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ìtàn yìí dá lérí ọkọ àti ìyàwó tí wọn kò ní sùúrù láti wá ọmọ lẹ́yìn ọdún mẹ́wàá.Wọ́n tọ Olódùmarè lọ.Ṣe ọ̀run kò jìnnà sí ayé nígbà náà. Olódùmarè ní kí wọ́n ní sùúrù pé ọmọ tó wà nílẹ̀ ìṣènìyànṣẹranko ni. Ṣùgbọ́n àìnísùúrù mú wọn gba irúfẹ́ ọmọ yìí.Bí ọmọ yìí kò ṣe pé tó, ìyáálé kò nífẹ̀ẹ́ rẹ̀.Èyí ló mú u kó ó pinnu láti fi òpin sí ìfẹ́ ọmọ yìí àti ọkọ rẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

1. Júwe ọ̀nà tí tọkọ taya inú ìtàn yìí fi rí ọmọ.
2a. Kí ni orúkọ ọmọ náà?
b. Júwe ìrísí àti ìhùwàsí ọmọ náà.
3. Irú orin wo ni ọmọ yìí máa ń kọ tí àwọn òbí rẹ̀ bá ti lọ oko tán?
4. Kí ni àwọn ẹ̀kọ́ tí ìtàn yìí kọ́ wa?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ibadan: Y-Books.

# ÌPÍN KẸRIN: ÌTÀN TANÍMỌ̀LA ÀTI OROGÚN ÌYÁ RẸ̀

**Àkóónú**

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Kíka ìtàn Ìtàn Tanímọ̀la àti Orogún Ìyá Rẹ̀
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ìfáárà yìí kò yàtọ̀ sí ìfáárà tí ó wà ní àwọn ìpín ìṣaájú

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Wo èròǹgbà àwọn ìpín ìṣaájú.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢAÁJÚ

1. Kí ni ìtumọ̀ orogún?

## 4.0 ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ka ìtàn tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí Ìtàn Tanimọ̀la àti Orogún ìyá rẹ̀

*Apàlọ́:* *Ààlọ́ o!*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Ààlọ́!*
*Apàlọ́:* *Ní ìgbàkan*
*Àgbálọ̀ọ́:* *Ìgbà kan ń lọ,*
*Ìgbà kan ń bọ̀,*
*Ìgbà kan kì í tán láyé*
*Apàlọ́:* *Ní ọjọ́ kan*
*Agbálọ̀ọ́:* *Ọjọ́ kanlòní jẹ́*
*Kórí jẹ́ ó jẹ́ ọjọ́ rere fún wa*
*Apàlọ́:* *Ní ìgbà kan*
*Apàlọ́:* *Obìnrin kan wà*
*Agbálọ̀ọ́:* *Ó wà bí ẹ̀wà*
*Apàlọ́:* *Ó bí ọmọbìnrin méjì,*
*Orogún rẹ̀ sì fi ọmọbìnrin kan sí ayé lọ.*

Orúkọ ọmọbìnrin tí ìyá rẹ̀ ti kú yìí ń jẹ́ Tanímọ̀la.Ṣé kò sí irú aṣọ tí arẹ́wà le wọ̀ kí ẹwà rẹ̀ móókùn. Obìnrin ọlọ́mọ méjì yìí ti gba àyà lọ́wọ́ ọkọ rẹ̀. Ohun tí ó bá sọ ni abẹ́ gé, òun ló tilẹ̀ ń ṣe bí ọkọ ní ọ̀dẹ̀dẹ̀. Ọmọbìnrin náà kò níwà olóókan, ó burú ju ikú tíí pa ni lọ. Ṣùgbọ́n onífọ̀n tí ó sọ pé inú òun kò dára ni, báwo ni ojú rẹ̀ ṣe rí ni ọ̀rọ̀ obìnrin yìí. Kì í ṣe ìwà nìkan ni kò ní, kò tún lẹ́wà náà. Ó burẹ́wà bí ìgbá, orí rẹ̀ rí féégbé bí ìkéémù ẹlẹ́wọ̀n. Ojú rẹ̀ rí kànngbọ̀n-kànngbọ̀n bí ìgbà tí erèé so ẹyọkan.Ẹsẹ̀ rẹ̀ rí fọn-ọnran bí kọ́bọ̀ sáré sí gọ́tà.Ó ṣe ìdí pẹlẹbẹ, ó sì ṣe apá kánndá bíi ti orogún ẹlẹ́ran.

Obìnrin yìí tún wá dára ju àwọn ọmọ rẹ̀ lọ, ṣé ẹni tí a bá sọ pé a ó jọ jíjù ni a máa ń jù ú. Èyí ló jẹ́ kí àwọn ọmọ tó jọ ìyá wọn bí ìmumu ya ojúlówó òburẹ́wà. Kò sí ẹ̀yà ara wọn tó ṣe é wò. Ṣùgbọ́n ọmọ dára ó dẹjọ́ ni ọmọ orogún ìyá wọn yìí. Ńṣe ló pọ́n wẹ̀ẹ̀ láti òkè dé ìsàlẹ̀. Kò sí àléébù kan ṣoṣo ní gbogbo ara rẹ̀.

Ẹwà ọmọbìnrin aláìsí yìí tí ó bùyààrì ni ó fi kún ìkórira tí orogún ìyá rẹ̀ àti àwọn ọmọ rẹ̀ ní sí i. Kò sí ohun tí Tanímọ̀la lè ṣe tí í dára lójú wọn. Bó bá wúkọ́ wọn á ló dá ogun, bó sì rẹ́rìn-ín wọn á ló kan ìjàngbọ̀n. Àní bí ó bá ń jẹun lásán wọn á ní ó ń bu òkèlè bí orí àbíkú.Wọn ṣá fi ayé ṣú Tanímọ̀la yìí. Kàkà kí bàbá rẹ̀ sì máa gbà á sílẹ̀ lọ́wọ́ ìyá tí ń jẹ bí ẹni jẹ iṣu báyìí, ńṣe ni bàbá yóò máa wò bí i ti ọ̀ọ́kán-ilé. Kì í ṣe ẹjọ́ bàbá, ṣebí a ti ṣàlàyé pé ìyàwó rẹ̀ ti fi orí rẹ̀ gba pààrọ̀.

Bí ibi ayẹyẹ kan bá wà, obìnrin burúkú yìí máa ń rú sínú aṣọ tó tinú aṣọ wá. Bẹ́ẹ̀ ló sì máa wọ àwọn ọmọbìnrin rẹ̀ méjéèjì ní ajínínrin aṣọ. Àkúgbó aṣọ láabi ni í kì bọ Tanímọ̀la lọ́rùn. Ṣùgbọ́n ohun tí ó tún ń ba obìnrin náà nínú jẹ́ ni pé ńṣe ni àwọn ọkùnrin máa ń ṣu Tanímọ̀la rànyìnrànyìn tòun tàkísà. Àwọn ọmọ tirẹ̀ kì í sì í rí ẹnìkan ṣoṣo pè wọ́n wò.

Ìdí ọ̀rọ̀ mà nìyí, tí orogún láburú yìí fi pinnu láti rán Tanímọ̀la ní ọ̀run ọ̀sán gangan. Èrò rẹ̀ ni pé nígbà tí àwọn tí ń wá a wá kò bá rí i mọ́, bóyá wọn yóò le máa wo ojú àwọn ọmọ òun. Bó bá ṣe pé obìnrin náà kúkú dúnbú Tanímọ̀la ni, ọ̀rọ̀ kì bá sàn. Ńṣe ló gbé agbè omi lé e lórí tí ó ní kí ó kọrí sódò lọ́jọ́ tí àwọn iwin ń ṣọdún wọn.

Báyìí ni Tanímọ̀la ṣe lọ sí odò tí kò bọ̀. Inú obìnrin náà sì dùn dé mùdùnmúdùn egungun. Èrò rẹ̀ ni pé odò ti gbé oníyẹ̀yẹ́ lọ, ìjà òun sì ti tán. Àṣe ewé ló ń bẹ lórí iṣu là ń bẹ̀rù kànyìnkànyìn, obìnrin yìí kò tètè mọ̀ pé ọlá ìkarahun ni ìgbín ń jẹ. Àní kò tètè mọ̀ pé ọlá Tanímọ̀la ni òun ń jẹ tí àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin fi ń dà gìrìgìrì nínú ilé òun. Bí Tanímọ̀la ṣe di àwátì báyìí ni oníkálukú wọn ti gbé jókòó sílé wọn. Ìbànújẹ́ wá dorí àgbà kodò. Inú obìnrin yìí kò wá dùn mọ́, bẹ́ẹ̀ sì ni ńṣe ni àwọn ọmọ rẹ̀ ń kanra gógó bí ajá elékùúkú.

Ẹ jẹ́ kí á wá wohun tó ti ṣẹlẹ̀ sí Tanímọ̀la lẹ́yìn tí ó ti bọ́ sọ́wọ́ àwọn iwin.Nígbà tí ó ròyìn ohun tí ojú rẹ̀ rí fún àwọn iwin, àwọn yẹn náà sì gbà láti ràn án lọ́wọ́. Báyìí ni wọ́n fún un lówó àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ọrọ̀. Ìlú rẹ̀ tí yóò wọ̀ báyìí ń̀ṣe ló bá a tí ọba ìlú rẹ̀ ṣẹ̀ṣẹ̀ ń gbadé.Bí ọba ṣe rí i nínú ọlánlá rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ló ní kí wọ́n sọ ọ́ di olórí àwọn olorì.Bí orí ṣe gbé e dé ibi ọlá nìyí.

Kò pẹ́ púpọ̀ tí Tanímọ̀la di olorì ni wàhálà ṣẹlẹ̀ sí orogún ìyá rẹ̀ àti àwọn ọmọ orogún náà. Ẹni kan kú sí wọn lọ́rùn, ńṣe ni wọ́n dì wọ́n ní àpànyàkà dé ààfin ọba. Wọn kò dá Tanímọ̀la mọ̀ mọ́. Ó yẹ kí wọ́n pa wọ́n ni. Ṣùgbọ́n Tanímọ̀la ló gbà wọ́n sílẹ̀.Ó sì tún ní kí wọ́n máa kóbọ̀ ní ààfin ọba.

Ẹ̀kọ́ tí ìtàn yìí kọ́ wa ni pé, kò yẹ kí á máa fi ìyà jẹ alaìlárá nítorí pé a kò mọ ẹ̀yìn ọ̀la.

| | |
|---|---|
| *Apàlọ́:* | *Kí àlọ́ mi gba orógbó jẹ*<br>*Kí ó má ṣe gba obì jẹ,*<br>*Orógbó ní í gbó ni sáyé*<br>*Obì á bì wọ́n sọ́run*<br>*Bí mo bá purọ́ kí ágogo ẹnu mi má ṣe ró ní ẹ̀ẹ̀mẹta*<br>*Bí n kò bá parọ́*<br>*Kí agogo ẹnu mi ró*<br>*Ó di pó! pó! pó!*<br>*Ó ró tàbí kò ró?* |
| *Àgbálọ̀ọ̀:* | *Ó ró!* |
| | Orísun ìtàn: Ọ̀pádọ̀tun (1994) |

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ìyá Tanímọ̀la ti kú.Tanímọ̀la jẹ́ ọmọ tí ó rẹwà púpọ̀ jù. Nítorí ẹwà rẹ̀, orogún ìyá rẹ̀ kò fẹ́ràn-an rẹ̀ rárá. Bákan náà ni àwọn ọmọ orogún ìyá rẹ̀ kórira rẹ̀. Wọ́n pinnu láti pa á. Orogún ìyá rẹ̀ rán an lọ sí odò níjọ́ tí àwọn iwin ń ṣọdún pẹ̀lú èrò pé àwọn iwin yóò pa á. Ṣùgbọ́n dípò kí àwọn iwin pa á, nígbà tí ó ròyìnara rẹ̀, wọ́n fún un lówó àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan orọ̀. Ọba rí i nígbà tí ó ń wọ ìlú, ó sì fi ṣe ayaba.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Dáhùn ìbéèrè wọ̀nyí:

1a. Wo ìpín kínní (paragraph 1) ìtàn yìí, ọnà-èdè wo ni ó jẹyọ níbẹ̀?
b. Ìgbà mélòó ni ọnà-èdè yìí jẹyọ?
2. Júwe ìwà àti ìrísí orogún ìyá Tanímọ̀la
3. Irú ọmọ wo ni Tanímọ̀la jẹ́.
4. Àwọn kókó wo ni o rí fàyọ nínú ìtàn náà.

5. Ṣe àgbéyẹ̀wò bátànì ìparí àlọ́ yìí. Àwọn ọnà-èdè wo ni ó jẹyọ níbẹ̀? Fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1994) *Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn*. Ibadan: Y-Books.